# A Mú Ki Àwọn Ìṣẹ̀lẹ̀ Yé Ni Nípa Àsọtẹ́lẹ̀

Jeffersonville, Indiana USA
Ọjọ Kinni, Osu Kẹjọ, 1965

1 Ẹ jẹ ki a tẹriba fun adura bayi. Oluwa Ọlọrun wa, Ẹlẹda nla ọrun oun aye, Ẹniti ó mu Jesu jade kuro ninu òkú, ti Ó sì wà pẹlu wa fun ẹgbẹrun odun meji yii, ti Ó wà laaye titi lati fi idi Ọrọ Rẹ̀ mulẹ, ki ó si mu u jẹ otitọ fun iran kọọkan. A dupẹ pupọ fun ifarahan Rẹ lati ọrun wa bayi, bi a se mọ eyi, wipe a ni idaniloju nla yii, wipe lẹyin ti aye yii ba kọja, a ni iye ainipẹkun ni aye ti o n bọ. Ẹ seun fun eyi, Oluwa. Ireti yii si mulẹ ni ọkan wa, ti o duro gbọingbọin ti o si daju ni igba ìjì. Nigbati ìjì ba si de, ti awọn igbi omi nla n yi, a mọ wipe nipa igbagbọ ninu Rẹ, a lee bori gbogbo ìgbì omi.

Ọlọrun, ran wa lọwọ ni asalẹ yii, bi a se wa lati se isẹ-iransẹ fun awọn alaisan ati awọn alaini. A gbadura, Ọlọrun, wipe ki yoo si alaisan kankan laarin wa nigbati a ba kuro ni asalẹ yii. Jẹ ki olukuluku gba iwosan nipa agbara Rẹ atọrun wá, nibi yii ati kaakiri orilẹ-ede yii, awọn ti o ngbọ wa nipa tẹlifoonu, ki a mase ri ẹnikẹni ti yoo jade kuro ninu gbọngan kan tabi ipejọpọ kan pẹlu aarẹ ni asalẹ yii. Jẹ ki Ẹmi Rẹ wo wọn san. Jẹ ki Òòrùn òdodo nla ni, pẹlu iwosan ni ìyẹ́ apa Rẹ, ki o yọ, ki o si tan itansan igbagbọ si ọkan kọọkan bi wọn se n feti si Ọrọ naa, ki wọn ri ifarahan Ẹmi Mimọ, ki o mú u da wọn loju wipe Oun si wa laaye. A gbadura fun awọn ibukun wọnyi, Baba, ni orukọ Jesu. Amin. (Ẹ lee joko.)

2 A ka eyi si anfaani nla lati wa nibi ni asalẹ yii leekansii lati ba awọn eniyan sọrọ ati lati gbadura fun awọn alaisan. A fẹ ki gbogbo awọn ti o wà ni ori ẹ̀rọ tẹlifoonu kaakiri gbogbo orilẹ-ede yii lẹẹkansii ni asalẹ yii. A si gbadura wipe ki Ọlọrun bukun ẹnikọọkan yin, bi a se n gbagbọ wipe gbogbo awọn ti o gba Kristi ni owurọ yii ni yoo kun fun Ẹmi Mimọ ki wọn si maa gbe igba-aye otitọ ati ododo fun-Un titi ti aye yoo fi dopin lori ilẹ aye, ani ara kíkú yii. Ati nipa síse bẹẹ, wọn ni ìyè ainipẹkun. Wọn ko ni kú laelae ni aye ti o n bọ, ani igba nla ti gbogbo wa n foju sọna fun.

3 Bayi a o sọ, bi mo se n ronu nipa rẹ, ki a mase di wa lọwọ. Arakunrin Vayle wa nibi, mo si le ma ri aaye rii. Se mo lè fi iwe ti a fi ọwọ kọ yẹn ransẹ si ọ nigbati mo ba pada de Tucson? Mo n yẹ ẹ wo lọwọ; n koi tii ka gbogbo rẹ tan, n o si fi ransẹ si ọ ni kete ti mo ba ti de Tucson.

Bayi, mo n fẹ lati se ifilọ kan. Eleyi wa fun awọn ijọ nibi gbogbo, paapaa julọ ni Iwọ Oorun, tabi ibikibi ti wọn ba ti fẹ wa. Arakunrin wa ọwọn, Arakunrin Pearry Green, pẹlu…. Oun ni o se agbatẹru wíwà ti a wa lori tẹlifoonu yii. Oluwa ti n fi si ọkan rẹ lati wa bẹ wa wo ni Tucson, ki o si bẹrẹ isọji ni Tucson, eyiti a nilo gidigidi. Arakunrin Pearry yoo si wa ni Tucson. Ti e ba fẹ ba wọn sọrọ, ki ẹ kan si ile-isẹ wa ti o wà nibẹ. Yoo jẹ ọjọ kẹwa, ikọkanla, ikejila ati ikẹtala osu kẹjọ. O ti wa ni ọkan rẹ̀ fun ìgbà pípẹ́, mo si sọ fun-un wipe ọna kan ti ó fi lee mu u kuro ni ọkan rẹ̀ ni ki ó lọ se e. Ó si jẹ arakunrin Kristẹni, iransẹ Ọlọrun tootọ. Ẹyin ti ẹ wa ni Tucson, mo mọ wipe a o bukun fun yin, bi yoo se maa waasu nibikan nibẹyẹn, boya ni ile-itura Ramada tabi ibikibi ti Oluwa ba ti pèsè aaye; koi tii sọ fun wa nibi. Sugbọn mo mo wipe a o bukun fun yin ti ẹ ba wa, ki ẹ si gbọ Arakunrin Green bi o se n si Ọrọ Ọlọrun payá fun wa, boya yoo tun gbadura fun awọn alaisan, tabi ohunkohun ti o ba wa ni ìlànà ami-ororo Ọlọrun lati se.

4 A tun fẹ dupẹ lọwọ Arakunrin Orman Neville ati Arakunrin Mann fun àkókò idapọ iyanu yii pẹlu wọn. Mo dupẹ pupọ lati ni idapọ pẹlu awọn eniyan bii Arakunrin Neville, Arakunrin Mann, ati gbogbo awọn oniwaasu nibi yii. Mo lero wipe a ti fi wọn han. Ti o ba jẹ wipe awọn igbimọ ati ijọ wa nibi ko ba tii fi yin han, o da mi loju wipe Ọlọrun da yin mọ nihin yii gẹgẹbi iransẹ Rẹ̀. Ki Oluwa maa bukun fun yin titi lae.

5 Bayi, a beere ohun kekere kan lọwọ mi nibi yii, ninu iwe kekere kan ti a fi fun mi lati…. Wọn se ipade awọn alabojuto ni alẹ ijelo nibi, igbimọ awọn alabojuto ati awọn diakoni, mo si lero wipe a ka akọsilẹ ipade naa ni owurọ yii niwaju ijọ. Ti eleyi si jẹ asa wa lati se bẹẹ. Ninu awọn ipinnu ti wọn se lati ọwọ igbimọ awọn alabojuto ati awọn diakoni ninu ijọ nihin, bi ẹ se mọ, wọn ko lee tẹ gbogbo eniyan lọrun. A ko lee se iyẹn. N ko ni nkankan se pẹlu igbimọ awọn alabojuto tabi igbimọ awọn diakoni. N ko tilẹ lee dibo ẹyọkan ayafi ti ọ̀mì bá wà, mo si nilati wa nibi lati se e nigbanaa; Arakunrin Orman Neville ni o ni ibo keji yẹn. Nigbanaa a nilati fi ọwọ si eyi, nitori a jẹ ara ijọ. Sugbọn ipinnu yoowu ti igbimọ awọn alabojuto ati awọn igbimọ wọnni ba se, a ti wọn lẹyin lẹkunrẹrẹ, nitori ohun ti wọn wa nibi fun niyẹn. Ipinnu wọn sì wà laarin awọn ati Ọlọrun. Emi ko lee, n ko lee, n ko si nii, fun idi kankan, tako ipinnu yẹn. Ohun kan tun ni, a fi ofin dè mí lati ọwọ Ijọba Amẹrika lati se ipinnu kankan nipa iyẹn, nitorinaa ẹ jọwọ ẹ mase sọ fun mi lati se atunse ipinnu wọn. N ko lee se iyẹn, n ko si fẹ gbọ nkankan nipa rẹ. Nnitorinaa, ẹ mase sọ fun mi lati se atunse ipinnu wọn. Ẹ ri awọn igbimọ; awọn ni o se ipinnu naa. O dara.

6 Bayi, ti ipade miiran yoo ba wa, o see se, ti Oluwa ba fẹ, n o pada wa sihin ni nkan bii ọ̀sẹ̀ mẹrin si mẹfa, tabi nkan bẹyẹn, boya fun ipade ọjọ Sọnde miiran. Mo si se ifilọ ni owurọ yii, mo fẹ sọrọ nipa Ọlọrun Fi Ara Han Ninu Ọrọ Rẹ, n ko si ní ní àkókò ni asalẹ yii, nitootọ, n ko ni ohùn ti o tó lati se e. Ati pẹlu awọn ọpọ ẹ̀rọ…. Awọn ti o wà ni ìta fẹrẹ tó awọn ti o wà ninu ile, tabi ki wọn ju bẹẹ lọ, ti a ba ka awọn ọkọ ẹ̀rọ ati ọkọ ẹ̀rù ati awọn to ku ti o wà ni ita, pẹlu awọn eniyan ninu wọn. Nigbati wọn si i, iwaasu naa ti gbẹnu soke diẹ sii,

a le gbọ́ ọ. Iwaasu ori afẹfẹ yii, ori afẹfẹ lati inu Ile-Ijọsin, a le gbọ ọ lati ibi ti o jinna diẹ. Awọn ọkọ kan si jinna diẹ si wa, awọn ọkọ̀ ti o tò lera wọn, lo sókè sódò, ati ni ayika pẹlu oju titi, ni ayika Ile-Ijọsin ni alẹ yii. N ko gbagbọ wipe igba kankan wa ri ti a ni awọn èrò ti o pọ to bayi ni ayika ijọ yii ju bi a se nii ni asalẹ yii lọ. Nitorinaa, a…. ọpọlọpọ ni o sì n wa ọkọ wá, ti wọn si n lọ.

Nitorinaa, iyẹn fi han wipe, "Nibiti ẹran tutu bá wà, ni awọn idi yoo pejọ pọ si." Ẹ si jẹ ki n sọ fun yin ni asalẹ yii, laarin ẹgbẹ awọn eniyan kekere yii, ipade agbaye ni. O fẹrẹ jẹ wipe ida meji ninu ida mẹta orilẹ-ede yii ni o ni asoju nihin, yatọ si awọn orilẹ-ede okeere marun-un, titi de Russia, ati kaakiri gbogbo orilẹ-ede yii. Titi de Venezuela, lọ si Jamaika, kaakiri ibi gbogbo ni orilẹ-ede, awọn eniyan wa nihin, wọn n pebi, wọn si n pọngbe fun Ọlọrun. Iru akoko iyanu wo niyi!

7 Bayi mo fẹ, ki n to ka Bibeli…. Se ẹ o gbadura fun mi bayi? N o gbiyanju lati mu iwaasu kekere kan wa, bi Oluwa ba fẹ, lori sise amulo iwosan lati ọrun wá. Nitori ni owurọ yii, a sọrọ lori igbala. Ati ni alẹ oni, a o sọrọ fun iseju diẹ lori iwosan lati ọrun wa, lẹyinnaa a o pe ila adura, a o si gbadura fun awọn eniyan. Bi a se n se iyẹn lọwọ, lori tẹlifoonu, ibikibi ti ẹ ba wa, ani ninu awọn ọkọ̀ èrò ati ọkọ̀ ayọ́kẹ́lẹ́ ni ayika ati tosi Ile-Ijọsin yii, nigbati asiko ba to lati gbadura fun awọn alaisan, ti ẹ kò ba lee wọ inu ile… Ti o jẹ wipe ẹ kò lee se e, iyẹn da mi loju bayi, nitori ẹnu ọna ati ibi gbogbo ti fun pọ, ko si si aaye nibikibi, nitorinaa ẹ gbadura ki ẹ si gbe ọwọ le ara yin ni ita nibẹyẹn. Ẹ si jẹ ki olukuluku oniwaasu ti o ngbọ wa lori tẹlifoonu ni asalẹ yii, gbadura fun ijọ rẹ nigbati ìsìn iwosan ba n lọ lọwọ. A gbagbọ wipe Ọlọrun wà kaakiri, nibigbogbo. Bayi ki a to ka tabi…

8 Ki a to gbadura, a fẹ ka diẹ ninu Ọrọ Ọlọrun. Mo si yi Iwe Mimọ ti mo fẹ ka pada laipẹ yii, nitori mo fẹ yi iru ipade ti mo ni lọkan fun asalẹ yii pada, nitorinaa mo ti yii pada diẹ; nitorinaa mo nilati yi Iwe Mimọ ti mo fẹ ka pada, kii kuku se wipe mo yi wọn pada, sugbọn mo se atunto wọn, ti iwosan lati ọrun wa, ki o lee ye awọn eniyan. Ẹ jẹ ki a si Luku Mimọ, ori kẹrinlelogun. A o si bẹrẹ lati ẹsẹ kejila ti ori kẹrinlelogun, a o si ka titi de ẹsẹ 34. O da lori ajinde Jesu Oluwa.

> *Nigbanaa ni Peteru dide, o si sare lọ si ibi iboji naa; nigbati o si bẹrẹ, o si ri awọn asọ ọ̀gbọ̀ naa … o n ro ninu ara rẹ, eyiti o wa si imusẹ.*
>
> *Si kiyesii, awọn meji ninu wọn n lọ si ileto kan ti a n pe ni Emmausi ni ọjọ naa, eyiti o to ọgọta ibùsọ̀ lati Jerusalẹmu.* [Bayi, ibùsọ̀ mẹwa ni o jẹ maili kan, nitorinaa o jẹ bii maili mẹfa.]
>
> *Bi wọn si se n ba ara wọn sọrọ nipa … awọn nkan wọnyi ti o ti sẹlẹ.*
>
> *…o si se, wipe bi wọn ti n ba ara wọn sọrọ ti wọn si njiroro, Jesu tikararẹ sunmọ tosi, Ó sì n ba wọn rin lọ.*
>
> *Sugbọn a ru wọn loju ki wọn ki o mase lee mọ̀ Ọ́.*
>
> *O si wi fun wọn wipe, Ọrọ kini ẹyin n ba ara yin sọ, bi ẹyin ti n rin, ti ẹ si banujẹ?*
>
> *Ọkan ninu wọn, ti a n pe ni Kleopa, si dahun wi fun-Un pe, Alejo saa ni Iwọ ni Jerusalẹmu ni, ti Iwọ kò si mọ ohun ti o sẹlẹ … ni awọn ọjọ wọnyi?*
>
> *O si wi fun wọn pe, Kini?*

9 [Bayi, ẹ ranti Jesu funra Rẹ niyi, O ti jinde, O n sọrọ.]@@ *Wọn si wi fun-Un pe, Ni ti Jesu ti Nasarẹti, ẹniti ise wolii, ti O pọ ni isẹ ati ni ọrọ niwaju Ọlọrun ati gbogbo eniyan:*

> *…bi awọn olori alufaa ati awọn alagba ti fi I lé wọn lọwọ lati da a lẹbi iku, ati bi wọn ti kan-an mọ agbelebu.*
>
> *Bẹẹni Oun ni awa ti ni ireti wipe Oun ni iba ra Israẹli pada: yatọ si eleyi pẹlu, oni ni ọjọ kẹta ti awọn nkan wọnyi ti sẹlẹ.*
>
> *Bẹẹni, awọn obinrin kan ninu ẹgbẹ wa si dá wa ni ìjì, awọn ti o tete de ibi iboji naa;*
>
> *Nigbati wọn ko si ri oku Rẹ, wọn wá, wọn si wipe, awọn ri iran awọn angẹli, ti wọn wi pe … Ó wà laaye.*
>
> *Awọn kan ti wọn wà pẹlu wa si lọ si iboji naa, wọn si ri i, gẹgẹbi awọn obinrin naa ti wi: sugbọn oun ni wọn ko ri.*

10 [Ẹ feti silẹ bayi!]

> [Jesu], *Nigbanaa ni O wi fun wọn wipe, Ẹyin ti oye ko ye, … ti o si yigbì lati gba ohun gbogbo ti awọn woliii ti sọ gbọ:*

*Ko ha yẹ ki Kristi ki o jiya awọn nkan wọnyi, ki Ó sì wọ inu ọgọ Rẹ lọ?*

*O si bẹrẹ lati Mose ati gbogbo awọn wolii, O tumọ nkan fun wọn ninu Iwe Mimọ gbogbo nipa ti ara Rẹ.*

*Wọn si sunmọ ileto ti wọn n lọ: Ó si se bi ẹni pe yoo lọ si iwaju.*

*Wọn si rọ Ọ, wipe, Ba wa duro: nitori o di ọjọ alẹ, ọjọ si kọja tan. O si wọle lọ, o ba wọn duro.*

*O si se, bi O ti ba wọn joko ti ounjẹ, o mu akara, o sure si i, o si bu u, o si fi fun wọn.*

*Oju wọn si la, wọn si mọ Ọ; O si nù mọ wọn loju.*

*Wọn si ba ara wọn sọ pe, Ọkan wa ko ha gbina ninu wa, nigbati O n ba wa sọrọ ni ọna, ati nigbati O ntumọ iwe mimọ fun wa?*

*Wọn si dide ni wakati kannaa, wọn pada lọ si Jerusalẹmu, wọn si ba awọn mọkanla pejọ pọ, nigbati wọn si wà pẹlu wọn,*

*Wọn wi pe, Oluwa ti jinde nitootọ, O si ti farahan fun Simoni.*

*Wọn si royin awọn ohun ti a se loju ọna, ati bi O se di mímọ̀ fun wọn nipa bibu akara.*

11 Bayi, ẹ jẹ ki a gbadura. Baba wa ọwọn, oloore-ọfẹ, a dupẹ lọwọ Rẹ fun Ọrọ Rẹ, nitori otitọ ni Ọrọ Rẹ, ìyè ni Ọrọ Rẹ. Iwọ, Oluwa, ọkan ni Iwọ ati Ọrọ Rẹ. Nitorinaa, a gbadura ni asalẹ yii, Oluwa, wipe ki O wa saarin wa ninu agbara ajinde Rẹ, ki O si fihan fun wa ni asalẹ yii, bii awọn ti o wa lati Emmausi, ki awa naa le pada si ile wa, wipe, "Njẹ ọkan wa ko ha gbina ninu wa?" Se fun wa, Oluwa; o tun ti di ọwọ irọlẹ lẹẹkan sii. Nitori a beere ni orukọ Jesu. Amin.

12 Bayi mo fẹ sọrọ nipa Bibeli yii. Koko iwaasu mi ni asalẹ yii, tabi akori, ni: A Mu Ki Awọn Isẹlẹ Yé Ni Nipa Asọtẹlẹ. A Mu Ki Awọn Isẹlẹ Yé Ni Nipa Asọtẹlẹ

Bayi, Bibeli jẹ iwe ti o yatọ si gbogbo awọn iwe mimọ. Bibeli jẹ iwe ti o yatọ. O jẹ iwe asọtẹlẹ, o n sọtẹlẹ, awọn ọhun ti o n bọ wa sẹlẹ ni ọjọ iwaju. O si tun jẹ Ifihan ti Jesu Kristi. Lati Gẹnẹsisi titi de Ifihan, o mu U jade ninu ẹkunrẹrẹ Rẹ, ohun ti Ó jẹ tẹlẹ, ati ohun ti O jẹ lọwọlọwọ. Gbogbo ẹkunrẹrẹ iwe naa…. Ifihan 1:1-3, sọ wipe iwe naa jẹ iwe Ifihan ti Jesu Kristi, eyi ti i se Ọrọ Ọlọrun - ifihan ti Jesu Kristi, Ọrọ Ọlọrun.

13 Bayi, gbogbo awọn iwe mimọ ti o ku, jẹ awọn ilana iwa ọmọluabi, awọn ilana iwa rere tabi awọn ilana ẹsin. Nkankan ti o jẹ wipe…. Ẹni melo ni o ti ka Kurani, Bibeli awọn Musulumi, ati iwe awọn ẹlẹsin Buddha, ati bẹẹ bẹẹ lọ? O kan jẹ ilana iwa titọ, bi o se yẹ ki awọn eniyan maa gbe, bi wọn se gbọdọ maa gbe igbe-aye wọn, sugbọn ko sọtẹlẹ, ko sọ ohun kan nipa awọn nkan wọnyi, tabi nipa wipe a fi ẹbun akanse fun ẹnikẹni, tabi ohun kan ti yoo sẹlẹ. O dabii wipe eniyan kan darapọ mọ ẹgbẹ kan lasan tabi nkankan. Nigbati awọn ijọ ba de ibi wipe wọn sọ ijọ wọn di ẹgbẹ kan lasan ti eniyan lee darapọ mọ, nigbanaa wọn ti kuro ninu Ọrọ Ọlọrun.

14 Nitori Bibeli jẹ ẹri aaye, ti a sọtẹlẹ nipa Jesu Kristi. Ati gẹgẹbi aye se dagba de ẹkunrẹrẹ rẹ̀, ti awọn àjàrà dagba de ẹkunrẹrẹ wọn, ti ọjọ́ dagba de ẹkunrẹrẹ rẹ̀. A fi Bibeli han ni ẹkunrẹrẹ Rẹ̀ ninu ẹniti Jesu Kristi jẹ; Oun ni Ọrọ Ọlọrun ti a fihan, gbogbo ẹkunrẹrẹ ìwé irapada. Bibeli jẹ Ọrọ Ọlọrun, o n sọtẹlẹ awọn nkan ti o n bọ wa selẹ lọjọ iwaju. Onkọwe naa pasẹ fun awọn onigbagbọ rẹ̀ lati kà ati lati gba gbogbo ọrọ rẹ̀ gbọ, ki i kan se apakan rẹ̀. Lati se àìgba Ọrọ kan gbọ, o dara ki o kuku mase gbiyanju mọ titi ti iwọ yoo fi gba Ọrọ yẹn gbọ. Olukuluku Ọrọ yẹn jẹ apakan Ọlọrun Olodumare - Ọlọrun ti o farahan, ti a kó jọ sinu Ọrọ Rẹ̀, lati fi ẹniti Ó jẹ́ han. A pasẹ fun wa, gẹgẹbi onigbagbọ, lati gba gbogbo ọrọ rẹ̀ gbọ́. Ọlọrun si ni Onkọwe naa funra Rẹ. Ko si ẹniti o lee fi ohun kan kun-un tabi yọ ohun kan kuro ninu rẹ. Ti o ba se bẹẹ, yoo sọ ara Ọlọrun di básubàsu. Boya yoo ni ika mẹfa ni ara ọwọ kan, tabi ki o ni ọwọ mẹta, tabi nkankan, lati fi nkankan kun-un; tabi lati mu nkankan kuro nibẹ, bii ki ó din ọwọ kan, tabi ki ó din ìka kan. Ẹkunrẹrẹ ara Jesu Kristi ni. Ati ninu Kristi, ti o jẹ akọ, ọkọ iyawo, iyawo naa wa ninu Rẹ pẹlu. Awọn mejeeji yii, ọkan ni wọn. "Ni ọjọ naa ni ẹyin yoo mọ wipe Emi wa ninu Baba, Baba si wa ninu Mi, Emi ninu yin, ati ẹyin ninu Mi." Aworan pipe ni eleyi!

Awọn onigbagbọ tootọ ninu Ọrọ yii, ti o gba bi o se ri, ti wọn gba a gbọ, ti wọn si n fi suuru duro de awọn asọtẹlẹ ileri rẹ, olukuluku wọn ti a o fi han ni iran rẹ. Gbogbo onigbagbọ ni o n foju sọna fun-un. Gbogbo awọn onigbagbọ ti o n nọga, ti wọn n sọna, ni awọn ti a fi í han fun.

15 Bayi ẹ wo igba ti Jesu Oluwa wá saye. Kini se ti awọn eniyan wọnyẹn kò mọ Johannu, nigbati Bibeli sọ gbangba nipa Isaiah wipe, "Ohun ẹnikan yoo wà ti n kigbe ni aginju, 'E pese ọna Oluwa silẹ'"? Wolii wọn ti wọ́n ni kẹ́yin, eyiti i se Malaki 3, sọ pe, "Kiyesii, mo ran ojisẹ mi saaju mi, lati pese ọna silẹ." Kini se ti wọn kò fi ri i? Nitori wọn n wo nkankan ti a ti se sẹyin, wọn gbe ironu wọn lori iwaasu kan ti o ti jade lọ tẹlẹ, wọn si

kuna lati ri ifarahan Ọlọrun lọwọlọwọ, ni ọjọ ti wọn n gbe inu rẹ.

Ẹyin Kristẹni nibigbogbo, ibi ti aye duro si lalẹ oni gan-an niyẹn. Laisi àtakò, otitọ niyẹn. Awọn Kristẹni, nibigbogbo, ngbiyanju lati boju wẹyin wo awọn ilana iwa rere kan ti Ọgbẹni Luther ti kọ, tabi Ọgbẹni Wesley, Sankey, Finny, Knox, Calvin, ti ẹnikẹni ninu wa ko lee sọrọ buburu nipa rẹ, sugbọn ọjọ ti o ti kọja niyẹn.

16 Awọn Farisi n pada wo ẹyin lati ri ohun ti Mose ti sọ, wọn si wipe, “Awa ni Mose. A ko mọ ibi ti Iwọ ti wa.”

Sugbọn ẹ ranti, nigbati Mose wa laye, wọn ko mọ ibi ti o ti wa, se ẹ rii. Bayi wọn…. Abajọ ti Jesu fi wi fun wọn wipe, “Ẹ se iboji awọn wolii lọsọ, ẹyin ni ẹ si fi wọn sibẹ.” Lẹyin ti ohun-isẹ-Ọlọrun fun ọjọ wọn ti lọ…. Ohun-isẹ-Ọlọrun kan yoo jade lọ, awọn eniyan yoo rii, wọn o si fi se yẹyẹ (awọn aye n se bẹẹ). Nigbati ojisẹ naa ba si ti setan, ti o si ti jisẹ rẹ̀, lẹyinnaa wọn o kọ́ ijọ ẹlẹkọ adamọ sori iwaasu naa. Wọn o si ku sibẹ, wọn ko lee jinde mọ.

17 Ẹ wo o ni isẹju kan, si ẹyin eniyan kan, paapaa julọ mo n ba ẹyin Katoliiki sọrọ. Njẹ ẹ mọ…. Njẹ ẹ ti ka itan tootọ, itan ijọ Aguda Katolliki? Bi o se jẹ wipe ninu akọsilẹ awọn ajẹriku, lati igba Augustine mimọ ti Hippo, oye milliọnu awọn eniyan alailẹsẹ ti ijọ pa? Mo gbagbe, n ko ranti oye rẹ gan-an, sugbọn ọpọlọpọ milliọnu ni, lati igba Hippo Mimọ ti…. Augustine Mimọ ti Hippo, Afrika, ti o polongo wipe ifẹ Ọlọrun ni lati pa ẹnikẹni ti o ba tako ijọ Aguda Katoliiki. Njẹ ẹ mọ wipe ninu iyẹn, wipe wọn kò ka Patrick Mimọ si nkankan ayafi igba ti o to kú, gẹgẹbi ọmọ ijọ Katoliiki? Ó tako póópù ati gbogbo ohun ti o n se, ijọ Katoliiki paapaa pa ẹgbẹẹgbẹrun awọn ọmọ tirẹ. Njẹ ẹ mọ wipe ijọ Katoliiki dana sun Joan ti Arc, obinrin eniyan mimọ yẹn, lori igi, nitori o jẹ … wọn sọ wipe àjẹ́ ni? Lẹyin igba ọdun, wọn wu oku awọn alufaa wọnyẹn, nigbati wọn rii wipe o kuna, wọn si da wọn sinu òkun, lai sin wọn sori ilẹ mimọ, lati se etutu.

Mase jẹ ki ọjọ yi fò ọ ru, mase jẹ omugọ.

18 Yoo wu awọn alufaa wọnyẹn lati jade wa ni asalẹ yii, awọn ti o da Jesu lẹbi. Ohun kan ni, wọn kò ri asọtẹlẹ ti wakati yẹn. Jesu wipe, “Ẹ wa inu Iwe Mimọ, nitori ninu wọn ni ẹ ro wipe” … tabi, “ni ẹ sọ wipe ẹ ni iye ainipẹkun, awọn Iwe Mimọ ni o si n sọ ẹniti Mo jẹ fun yin,” fun wakati yẹn.

Kiyesii, Bibeli ko lee kuna. Ohun kan ti ko lee se niyẹn - pe ki Ọrọ Ọlọrun kuna - nitori o sọ asọtẹlẹ ìse Ẹniti o ko Ọ́, ki Ó to se e.

19 Bayi, aaye bintin ni o wà fun ẹnikan lati sọ asọtẹlẹ wipe nkankan yoo sẹlẹ, ki o si sẹlẹ. Sugbọn ti o ba tun wa sọ ibi ti yoo ti sẹlẹ, boya iyẹn yoo fun-un ni aaye ẹyọkan ninu ẹgbẹrun mẹwaa. Ti o ba sọ ọjọ ti yoo sẹlẹ, iyẹn yoo tun din ku si aaye kan ninu miliọnu kan. Ati ẹni ti yoo sẹlẹ si, iyẹn tun jaa walẹ si aaye kan ninu biliọnu.

Sugbọn Bibeli yii sọ fun ọ ni pato, ẹni naa, ibi ti yoo ti sẹlẹ, nibo ni, ati ohun ti a lee foju sọna fun, kò sì fi igba kan kuna ri. Nitorina, ninu ifọrọwerọ kekere kan laipẹ yii, pẹlu alufaa ijọ Sacred Heart nibẹyẹn, o ni, “Ọgbẹni Branham, o ngbiyanju lati fi Bibeli jiyan.” O ni, “Itan ijọ niyẹn.”

Mo ni, “Ki i se itan kan; Ọlọrun funra Rẹ ti a kọ sinu iwe ni.”

O ni, “Ọlọrun wa ninu ijọ Rẹ.”

Mo ni, “Inu Ọrọ Rẹ ni Ọlọrun wa. Ohunkohun ti o ba si lodi si I, jẹ ki o jẹ irọ. Nitori o wipe, 'Jẹ ki Ọrọ Mi jẹ otitọ, ki gbogbo ọrọ eniyan jẹ irọ.'”

O ni, “Ko yẹ ki a jiyan.”

Mo ni, “N ko fi igba kankan sọ wipe ki o jiyan, sugbọn Bibeli wipe, 'Ẹ wa, ẹ jẹ ki a jọ sọ asọye pọ.'”

20 O sọ asọtẹlẹ ise Ẹniti o kọ ọ́, ki O to se e. Nitorinaa, ni sisọ iyẹn, iyẹn mu ki gbogbo ọkunrin ati gbogbo obinrin wa si ibi itẹ idajọ, laisi awawi kankan. Ti iwọ ba gba ohun ti awọn ijọ Eleto sọ nipa rẹ, ohun ti awọn Onitẹbọmi sọ nipa rẹ, ohun ti Katoliiki sọ nipa rẹ, ohun ti awọn Afede-ajeje-sẹri-Ẹmi-Mimọ sọ nipa rẹ, tabi ijọkijọ miiran, iwọ yoo ba ijakulẹ pade nibi idajọ. Sugbọn ti o ba kiyesi ohun ti Bibeli sọ wipe yoo sẹlẹ, nigbati o ba si sẹlẹ, nigbanaa iwọ yoo mọ ohun ti o sẹlẹ.

Bayi, ko han ni gbangba de ibi wipe gbogbo eniyan lee ri i, nitori Jesu dupẹ lọwọ Ọlọrun wipe O fi pamọ kuro loju awọn ọlọgbọn ati oloye, Ó si fi han awọn ọmọ ọwọ, awọn ti o setan lati kẹkọ. Ẹ ronu nipa Ọlọrun Olodumare ti O joko sinu Ọrọ Rẹ, pẹlu agbara lati bu ifọju lu awọn ọ́lọ̀rọ̀ ati awọn ọmọwe alaibikita, o fọ wọn loju ki wọn ma baa ri I, O si la oju awọn talaka ati awọn alaimọkan.

21 Ẹ kiyesi awọn eniyan wọnyi lati Emmausi, O ni oye wọn nipa Oun ni a dá duro. Wọn ba A sọrọ, wọn kò si mọ ẹniti Ó jẹ́, ni gbogbo ọjọ. Ọlọrun lee se iyẹn, nitori Oun ni Ọlọrun.

Ohun ti O se si awọn alufaa yẹn gan-an niyẹn, awọn akọwe yẹn, nitori a ti kọ ọ wipe Ó nilati se iyẹn. Ọlọrun fọ wọn loju ki awa baa lee ri aaye. Ẹ kiyesii, wọn ko lee riran, ko si bi wọn se ka iwe to, bi wọn se jẹ alufaa to, ohun ti wọn ti se, sibẹ wọn ko lee ri I, nitori wọn fọju. O seese ki oju wọn riran kedere, ni ti ara. Sugbọn oju ẹmi wọn!

22 Ohun kannaa ni mo ngbiyanju lati sọ ni owurọ yii nipa iwa pansaga awọn obinrin, bi wọn se n mura bayi. Wọn jẹ pansaga. Ninu Iwe Ọlọrun, wọn jẹbi iwa pansaga ni gbogbo igba ti wọn ba ti wọ asọ ti o jọ ti asẹwo. Ọkan wọn ko mọ o. Mo gbagbọ wipe awọn obinrin yẹn, ọpọlọpọ wọn, ẹgbẹẹgbẹrun wọn ni kò dẹsẹ, wọn kò sì ní i se pansaga rara. Ati awọn obinrin wọnyi, pẹlu ẹnikan ti o gba wọn laaye lati se e ki wọn si mu u jẹ, lai tu asiri wọn, ki wọn si sọ otitọ, wọn se pansaga. Eyiti Bibeli wipe, “Agbere ti o joko lori omi pupọ, ti gbogbo awọn ọba aye ati awọn eniyan aye, awọn ijọ ati bẹẹ bẹẹ lọ, n se agbere ti ẹmi pẹlu rẹ. Oun si ni iya awọn agbere” - ijọ ẹlẹkọ adamọ.

23 A n kiyesi Bibeli, nitori Ọlọrun kò fi wá silẹ ninu okunkun. O fi Bibeli ransẹ lati sọtẹlẹ fun wa, awọn isẹlẹ, ki wọn to sẹlẹ, ati bi wọn yoo se ri, ati akoko ti wọn yoo wa.

Bayi, o dabi igba ti eniyan ba wo iwe ti o n ka-ọjọ́-ka-osù, lati wọ ọjọ wo ni a wa. Ti o ba ro wipe eleyi jẹ́…. “Se Satide ni eyi ni, tabi Sọnde, kini?” Wo iwe ka-ọjọ-ka-osu. Iwe ka-ọjọ-ka-osu yii yoo sọ fun ọ, ọjọ ti ó jẹ́. Nigbati ẹ ba ri isesi awọn eniyan, boya wọn n lọ si ile-ijọsin, ti ẹ ri … gbọ agogo ti o n dun, yoo ya yin lẹnu wipe ọjọ wo ni. Wo iwe ka-ọjọ-ka-osu, yoo sọ fun ọ, ọjọ wo ni.

24 Nigbati ẹ ba si ri ijọ ti o n dabi aye, gẹgẹbi o se ri ni ọjọ Sodomu, ti ẹ ri awọn ijọ aye ti wọn n sin ọlọrun iran buburu yii, ti ẹ si ri iyẹn; ti ẹ si tun ri awọn ẹgbẹ kekere kan ti wọn pejọ pọ labẹ imisi Ọlọrun, ti wọn tun n fi igbe aye Jesu Kristi han, nipa awọn Iwe Mimọ ti o yẹ ki o sẹlẹ, ẹ mọ wakati ti a n gbe inu rẹ.

Bibeli sọ nipa asọtẹlẹ, ọjọ ti a wà ninu rẹ̀, ati akoko ti a wà ninu rẹ̀, ati iru awọn nkan ti o yẹ ki o maa sẹlẹ. Ó sọtẹlẹ nipa rẹ lẹkunrẹrẹ, kò sì yọ iran kankan silẹ ni gbogbo igba. Kò fi igba kankan kuna ri, ko si lee kuna, nitori awọn ti a ti yan tẹlẹ lati ri i, yoo ri i. Jesu wipe, “Ko si ẹni ti o lee tọ Mi wa, ayafi ti Baba Mi ba faa, ati gbogbo awọn ti Baba ti fi fun Mi, yoo wa.” O jẹ Ọrọ ti o n so pọ mọ Ọrọ. Ko lee se nkan miiran. A mọ ọjọ ti a n gbe inu rẹ.

25 Sugbọn bi o se ri ni gbogbo iran, awọn eniyan n jẹ ki wọn fi itumọ ti ara wọn sinu Ọrọ yii, ó si n mú ki wọn fọju si awọn isẹlẹ ti o n sẹlẹ. Ohun kannaa ni o sẹlẹ pẹlu awọn Farisi ati Sadusi. Nigbati Pọọlu duro sibẹyẹn ti o si gbiyanju lati sọ Iwe Mimọ, ọkunrin kan si gba a loju nitori o pe olori alufaa ni ògiri ti a kùn lẹ́fun. Nipa bẹẹ wọn kuna lati ri Ọlọrun ti O n fi idi Ọrọ asọtẹlẹ Rẹ mulẹ.

26 Se ẹ rii, Bibeli ko tako ara Rẹ; Bibeli ni Ọlọrun. Kò sí àtakò ninu Ọlọrun; Ó pé.

Sugbọn awọn eniyan pẹlu itumọ tiwọn! Ẹ kiyesii bayi, ẹ jẹ ki n fi han yin, ẹyin ọrẹ. Awọn ijọ paapaa kò gbà pẹlu ara wọn lori itumọ rẹ̀. Awọn ijọ Eleto ko gba pẹlu ijọ Onitẹbọmi, ijọ Onitẹbọmi ko gba pẹlu ijọ Alagba, ijọ Alagba ko gba pẹlu ijọ Afèdè-àjèjì-sẹri-Ẹmi-Mimọ. Ati pẹlu bii ogoji ijọ Afede-ajeji-sẹri-Ẹmi-Mimọ ti o yatọ si ara wọn, wọn kò lee gba pẹlu ara wọn. Nitorinaa, se ẹ rii, Babiloni tun niyẹn lẹẹkan sii, idaru-dapọ.

Sugbọn Ọlọrun ni o n tumọ Ọrọ ara Rẹ. O se ileri ohun naa, yoo si wa se e funra Rẹ. O fun (ara Rẹ) ni itumọ rẹ, nitori O fi ara Rẹ han ni wakati yẹn. Ara Kristi ti rin jinna to, lati ẹsẹ de ori!

27 Ẹ kiyesii, idi niyẹn ti awọn eniyan wọnyi fi kuna lati ri i, nitori wọn n fetisi ohun ti ẹlomiran sọ nipa rẹ, dipo ki wọn ka Ọrọ naa bi Jesu se sọ wipe ki wọn se. “Awọn ni o si n jẹri nipa Mi. Ẹ wa inu Iwe Mimọ, ninu wọn ni ẹ ro wipe ẹ ti ni iye ainipẹkun, awọn ni o si n jẹri nipa Mi.” Iyẹn ni wipe, ẹ gbọ, “Ẹ ka Iwe Mimọ ki ẹ si ri ohun ti Messiah yẹ ki o se. Ẹ wo igba ti o yẹ ki Messiah wá. Ẹ wo ẹni ti o yẹ ki o saaju bibọ Messiah. Ẹ wo wakati naa. Ohùn ẹnikan ti n kigbe ni aginju nilati wà: Johannu. Ẹ si ti se sii gẹgẹbi ohun ti ẹ ti kọ silẹ. Ẹ wo ohun ti o yẹ ki N se nigbati Mo ba de. Ni bayi, kini ẹ ti se? Se Mo ti kuna lati ba eleyi mu? Se ẹ rii, Jesu lo nsọrọ, ”Se Mo kuna lati ba eleyi mu?“

28 Ẹ kiyesii, bi a se n wọ inu Iwe Mimọ ni ọsan yii, bi ohun gbogbo ti a sọtẹlẹ nipa Rẹ se sẹlẹ gan-an bi o se yẹ ki o sẹlẹ. O yẹ ki wọn ti mọ isẹlẹ yii. “Gba-wèrè-mẹ́sìn, ọdọmọkunrin yii dide, bii ọmọ ọdun mẹtalelọgbọn … tabi ọmọ ọgbọn ọdun, o si lọ si ibẹyẹn, o n sọ wipe imọlẹ ati adaba n goke. Ati kini, itiju nla ni.” Wọn sọ pe, “A bi I lati ọwọ awọn obi ti ko ba ofin mu, O si n sọ wipe a bi Oun lati ọwọ wundia.”

Se ko yẹ ki wọn mọ wipe Isaiah sọ pe, ni Isaiah 9:6, “A bi ọmọ kan fun wa”? Se ko yẹ ki wọn tun mọ wipe wolii Isaiah sọ pe, “Wundia kan yoo loyun.” O yẹ ki wọn ti mọ awọn nkan wọnyi. Sugbọn, se ẹ rii, ohun ti o wa nibẹ ni wipe, wọn n ti i si ọjọ iwaju. Ati wipe ọkunrin yii, loju tiwọn, ko ba ohun ti wọn n fẹ mu. Sugbọn Ó sọ fun wọn, “Ẹ wa inu Iwe Mimọ, nitori ninu wọn ni ẹ ti rò wipe ẹ ni iye ainipẹkun, awọn ni o si n jẹri nipa isẹ-iranse iwaasu Mi.” Ki i se ohun ti ẹlẹkọ ẹ̀sìn kan sọ, sugbọn ohun ti Ọlọrun (ninu Ọrọ Rẹ) sọ wipe yoo sẹlẹ! Amin!

Bẹẹ naa ni bayi. Ẹ wa inu Iwe Mimọ, nitori awọn ni o n sọ wakati ti a n gbe inu rẹ, wọn n sọ fun wa ni pàtó, ohun ti yoo sẹlẹ lọjọ oni. Awọn ni o yẹ ki ẹ gbẹkẹ le, nitori awọn ni o n jẹri ẹni ti Jesu Kristi jẹ. Nitori Bibeli sọ wipe “Ọkannaa ni lana, loni, ati titi laelae,” nitori Oun ni ifihan Ọrọ ti iran yii. Ko lee yatọ.

29 Nitorinaa, nipa fifi eti si itumọ eniyan, wọn ri ifidimulẹ Ọrọ Ọlọrun, wọn si kuna lati rii. Nitori o nsẹlẹ ni gbogbo igba, sugbọn nitori wọn feti si…. Jesu si wipe, “Wọn jẹ afọju adari.” Ti afọju ba si n dari afọju, kini yoo sẹlẹ si wọn? Ẹ ranti bayi, Bibeli ti sọtẹlẹ wipe igba oniwaasu iran Laodikea yii fọju. Wọn ti lé Oun si ita ijọ. Kò sí iran miiran mọ, igba ijọ miiran ninu eyiti Jesu wa ni ita. Sugbọn igba ijọ Laodikea, Ó wà ni ita, O ngbiyanju lati wọle pada, “Mo duro lẹnu ilẹkun, Mo si nkankun.” O yẹ ki Ó wà ninu ile. Sugbọn O sọ wipe, “Nitori iwọ wi pe 'Emi ni ọrọ, mo si n pọ si i ni ọrọ, emi ko si se alini ohun kan,' ko si mọ - ko mọ - wipe afọju ni ọ, ti o ndari afọju, talaka ninu ẹmi, osi, are, ihooho, ko si mọ̀ ọ́.” Iru ki…. Ti ẹnikan ba wa ni ihooho ni oju titi, ti o jẹ ẹni osi, afoju, ti o si mọ wipe o ni ọpọlọ pipe, ti ẹ ba sọ fun-un wipe ó wà ni ihooho, yoo gbiyanju lati se nkanan nipa rẹ. Sugbọn ti o ba gbọnri, ti o sọ wipe, “Emi ko nii gba. Tani iwọ lati sọ ohun ti o yẹ ki n se fun mi? Mo mọ ibi ti mo duro si.” Ti iyẹn kii ba se ipo ikaanu, n ko mọ. Ohun ti Ọlọrun Bibeli yii sọ wipe ijọ yoo wa niyen, ni iran buburu yii bayi, ni igba ijọ ti o kẹyin ti a n gbe.

Ẹ kiyesii, sugbọn awọn eniyan, “Iye awọn ti Mo ba fẹran, ni Mo n ba wi.” Bayi ti Oluwa ba ba ọ wi, nipa ohun ti o n se, jade kuro ninu rẹ nigbanaa. Kuro nibẹ. “Iye awọn ti Mo ba fẹran, ni Mo n ba wi.”

30 Bayi, wọn n ri Ọlọrun. Bayi, ti o ba jẹ wipe awọn Farisi wọnyẹn sọ wipe, “Ẹ duro na. Ọkunrin yẹn ti fun wa ni ipenija gidi; O ni, 'Ẹ wa inu Iwe Mimọ, nitori ninu wọn ni ẹ rò pé ẹ ni iye ainipẹkun, wọn si njẹri nipa Mi.' O dara ki n pada wo inu Iwe Mimọ ki n si wadi ohun ti O yẹ ki o se, eni ti Ó jẹ́, kini o ye ki o sẹlẹ. O yẹ ki n pada lọ se iwadi.” Dipo iyẹn, wọn tọ alufaa lọ, wọn si beere lọwọ rẹ, “Ki ni o ro nipa rẹ?” Se ẹ ri iyatọ yẹn? O yẹ ki wọn ti maa ka Ọrọ yẹn.

31 Ni Heberu 1:1, Bibeli wipe, “Ọlọrun, ni igba atijọ” - igba atijọ niyẹn - “ati ni oniruuru ọna, kọ Bibeli nipase awọn wolii.” Ẹ kiyesii bayi, Ó kọ Bibeli nipase ọna ti Oun yàn, se ẹ rii. Bayi, ko nilo lati kọ ọ ni ọna yẹn, bẹẹni ko nilo lati gba eniyan là nipa ẹ̀jẹ̀. Kò nilò lati waasu ihinrere nipasẹ eniyan; O lee jẹ ki oorun, tabi osupa tabi awọn irawọ waasu Ihinrere; o lee jẹ ki awọn afẹfẹ kun pẹlu Ihinrere. Sugbọn O yan eniyan. O si yan ọna ti Ọrọ Rẹ gbà wá, iyẹn si jẹ nipasẹ awọn wolii Rẹ ti a ti yan tẹlẹ ti a si ti pese silẹ, ti wọn jẹ apakan Ọrọ Ọlọrun, wọn n fi ifihan Ọrọ Rẹ han si iran yẹn ni akoko yẹn. “Nitori Ọrọ Ọlọrun tọ awọn wolii wa nikan.” Ko fi igba kankan tọ ẹlẹkọ ẹsin wa ri. Ẹ fi han mi ninu Iwe Mimọ. Awọn wolii nikan ni O maa n tọ wa. Ọlọrun ko lee purọ. Nitorinaa Ọlọrun kọ Bibeli nipa ọna ti o yan, ati awọn wolii Rẹ ti O yàn; kii se awọn wolii ti eniyan yan, sugbọn awọn wolii ti Ọlọrun yan.

32 Nigbanaa awọn onigbagbọ rẹ n foju sọna fun imusẹ ohun ti wolii wọn sọ, iyẹn si ni ifihan wipe wọn jẹ wolii Ọlọrun. Nitori lakọkọ, a mi si wọn. Lẹyinnaa, wọn sọ ohun ti Ọrọ wakati naa sọ gan-an. Awọn ohun idanimọ rẹ niyẹn. Se ẹ rii, a lọ ninu iyẹn ni Sọnde to kọja. Ọpọ awọn wolii eke ni yoo dide. A si fun wa ni apẹẹrẹ ti Balaamu ati Mose, ti awọn mejeeji ni ami-ororo nipa Ẹmi kannaa, ọkan ninu wọn sọ wipe, “Ọkannaa ni gbogbo wa. Ẹ jẹ ki a darapọ, ki a ko awọn ọmọbinrin wa ati gbogbo wọn papọ. A ni awọn arẹwa obinrin nihin, ẹyin ọmọkunrin, ẹ wa sihin ki ẹ wa mu iyawo ti o dara fun ara yin. O dara bẹẹ, eniyan kanna ni gbogbo wa, lọnakọna, iran kannaa.” Ọlọrun ko dari ji wọn fun-un rara. Wọn feti si iyẹn.

Se ẹ rii, aye ati awọn eniyan n foju sọna fun ọna abayọ kekere kan, ọna ẹ̀bùrú kekere kan, ọna àbùjá kekere kan, sugbọn ko si abuja ninu Ọrọ Ọlọrun. Ilana kansoso ni o wà. Iwọ ni ki o gbé ara rẹ, ki o bá ilana naa mu, kii se ki o gbiyanju lati gbé ilana naa ki o lee ba iwọ mu. Gbogbo eniyan nilati se iyẹn. Ọna kansoso ti Ọlọrun si ni lati se e niyẹn.

33 Ẹ kiyesii, bayi, awọn onigbagbọ n duro de Ọrọ yẹn ki a mu U sẹ. Se ẹ rii, kii se eniyan ni o kọ ọ, sugbọn nipasẹ Oluwa Ọlọrun, nitorinaa, kii se iwe eniyan.

Ẹnikan sọ pe, “Iwe akọsilẹ awọn Heberu lasan ni.” Se awọn Heberu yoo kọ iwe ti o da awọn funra wọn lẹbi? Njẹ orilẹ-ede Juu ti o dara yẹn, awọn alákọ ati ọlaju, se wọn yoo kọ aisedeedee ara wọn silẹ, ki wọn si maa da ara wọn lẹbi? Dajudaju, bẹẹkọ. Ki o sọ ẹsẹ ara rẹ, bi wọn se lọ sinu ibọrisa, bi wọn se se agbere si Ọrọ Ọlọrun? Rara. Rara, wọn ko ni sọ iyẹn laelae, orilẹ-ede ti o gberaga yẹn.

Kii se iwe eniyan; iwe Ọlọrun ni. Awọn ọkunrin ti o si n ri iran ati ti wọn si n gbọ ohun Ọlọrun, ko loye rẹ (lọpọ igba) funra wọn, ni ọpọlọpọ isẹlẹ, se ẹ rii. Kii se eniyan ni o kọ Bibeli. Ọlọrun ni o kọ Bibeli. Kii se iwe eniyan; iwe Ọlọrun ni. Awọn èrò Ọlọrun ti a fihan nipasẹ ètè eniyan ni. Ohun ti o fi jẹ Bibeli niyẹn. Èrò ti a fihan ni ọrọ. Ni atetekọse ni èrò Ọlọrun si ti wà, O fihan nipasẹ ètè awọn wolii Rẹ, O si fi idi rẹ mulẹ nipasẹ awọn iransẹ Rẹ, se ẹ rii. Ẹ kiyesii.

34 Ọlọrun ni o n yàn funra Rẹ, nipa iyantẹlẹ, O yan awọn wolii fun iran kọọkan. Ẹ kiyesii. O se isẹda wolii yẹn lati ba iran yẹn mu. Se ẹ rii, O se isesi rẹ, ohunkohun ti o n se. O mu u yẹ, boya o ka iwe tabi kò ka iwe.

O mu awọn ẹbun naa yẹ, ọna ti yoo gba waasu, awọn ẹbun ti yoo ni, ati isẹ-ohun-Ọlọrun fun iran yẹn ni pato. Ọlọrun ti se iyantẹlẹ wipe nkan yẹn yoo sẹlẹ, ko si si ohun miiran ti o lee dipo rẹ. Emi ko bikita ohun ti o jẹ, oye aseyọri eniyan ti o wa, ko si ohun kan ti o lee dipo rẹ. O lee yan tẹlẹ wipe ki ẹni yẹn jẹ ope, O si lee yan-an tẹlẹ lati jẹ iru eniyan miiran. Ohunkohun ti o jẹ, yoo fun-un ni aaye rẹ, awọn ẹbun rẹ, yoo fun-un ni iwa-ẹda rẹ, ọna ti o n gba se nkan, ati ohunkohun ti o n jẹ, bi o se n fi ara rẹ han, ati ohunkohun ti o n se. O n jẹ ki ọkunrin akoko naa mu awọn eniyan akoko naa. Bẹẹni. O maa n se e.

Ni opin iran kọọkan, nigbati ijọ ti pada sinu aye ati ẹsẹ, ti wọn si n duro lori itumọ ti eniyan fun Ọrọ Ọlọrun…. Bi o se maa n ri, nigbagbogbo, ni opin iran kan, wọn maa n bọ sinu ibajẹ nipasẹ awọn ẹlẹkọ ẹsin ati awọn alufaa wọn, titi ti gbogbo rẹ yoo fi bajẹ tan. Nigbagbogbo ni itumọ wọn maa n lodi; ko si igba kan ti o kuna lati lodi ri. Ko si si igba kan ti Ọrọ Ọlọrun kuna lati tọna ri. Iyatọ rẹ̀ niyẹn.

35 Bayi, ẹ rii, Ọlọrun funra Rẹ ni o kọ Bibeli. Bayi, Ọlọrun lee sọrọ. Mose sọ wipe O ba oun sọrọ. Jeremiah sọ pe, “O fi ọrọ si ẹnu mi.” Ọlọrun tun lee kọwe. O kọ awọn Ofin Mẹwa pẹlu ika ara Rẹ. O kọwe sara ogiri ni Babiloni. Ẹ si ranti, ni Majẹmu Laelae nikan, ẹgbàá ìgbà ni awọn wolii sọ wipe, “Bayi ni Oluwa wi!” Ọlọrun lee sọrọ, Ọlọrun lee kọwe. Dajudaju. O fẹrẹ jẹ wipe ida aadọrun ninu ida ọgọrun iwe Matteu, Maaku, Luuku ati Johannu ni o jẹ Ọrọ Ọlọrun funra Rẹ, ti Jesu Kristi n sọrọ. Nitorinaa, ti Ọlọrun ba lee kọwe, ti Ọlọrun ba lee kawe, ti Ọlọrun ba lee sọrọ, se ko lee mu ki awọn ẹlomiran se bakannaa ni? Se ko sọ fun Mose wipe, “Tani o da odi, tani o si fun eniyan ni ọrọ?” Ọlọrun kọ Bibeli nipasẹ awọn wolii, ona ti O n gba se é.

36 Bayi, gbogbo igba ti ijọ ba ti da nkan ru (Ọlọrun si mọ tẹlẹ wipe wọn yoo se bẹẹ, nitori O mọ ohun gbogbo tẹlẹ), nitorinaa O ti pese wolii Rẹ kan pato silẹ fun iran yẹn, lati pe awọn ayanfẹ Rẹ nipa Ọrọ isẹ-ami ati isẹ-iyanu Rẹ ti o fi han, ati ifidimulẹ Ọrọ Rẹ, “O n fi idi Ọrọ naa mulẹ nipa awọn isẹ-ami ti o n tele e,” gegeḅi o ti se ileri. O maa n fun ni ní itumọ tootọ lẹyin ti a ba ti fi wolii naa han.

Gbogbo wọn lo korira rẹ, yatọ si awọn - awọn ayanfẹ - awọn ẹniti a ran-an si. Bayi, ẹ yẹ awọn isẹlẹ kọọkan wo bi ko ba ri bẹẹ. Awọn ti a ran-an si nikan! “O tọ awọn Tirẹ wá, awọn Tirẹ kò si gbà Á; sugbọn iye awọn ti o gbà Á, awọn ni Ó fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun.” Ẹ kiyesii, gbogbo ayẹwọ Ọrọ naa, ni gbogbo igba, ati ni opin iran kọọkan tabi ikorita kọọkan, gẹgẹbi mo se waasu lori rẹ ni ọpọ igba….

37 Ẹ wo igba Noah, ni opin rẹ saaju idajọ. Ki lo sẹlẹ? Noah, awọn ẹbí rẹ̀ nikan ni o gba ọkunrin yẹn gbọ. Awọn to kù nse atako rẹ. O si pa gbogbo aye rẹ.

Ni ọjọ Abrahamu, ẹgbẹ Abrahamu nikan ni o gbagbọ. Nigbati awọn angẹli naa lọ waasu fun Sodomu, Lọọti nikan ati iyawo rẹ pẹlu ọmọbinrin meji ni o jade, obinrin naa si pada di ọwọn iyọ.

Ni ọjọ Mose, awọn ayanfẹ Israẹli nikan ni o jade. Farao si korira rẹ.

Ni ọjọ Elijah, (o fẹrẹ jẹ wipe) gbogbo wọn, ayafi ẹgbẹrun meje, gbogbo wọn lo korira rẹ, gbogbo orilẹ-ede yẹn.

Ni ọjọ Jeremiah, eese, wọn sọ èso ti kọ̀ pọn si i, wọn si pè é ní gba-wèrè-mẹ́sìn, nitori o fi ẹgbẹ kan lélẹ̀ fun ọjọ pupọ, ati ẹgbẹ keji, o si mu awọn nkan, o fi wọn se àmì. Wọn korira rẹ̀.

Isaiah wolii, o da iran yẹn lẹbi de ibi wipe wọn fi ayùn rẹ́ ẹ si meji. Bẹẹni.

38 Johannu Onitẹbọmi. “Okunrin ara igbo kan nibẹyẹn, wèrè alariwo kan ni.” Gbogbo wọn, yatọ si awọn ọmọ ẹyin ti o fi han fun Jesu Kristi gẹgẹbi ijọ, “Oun niyẹn!” Johannu pese awọn eniyan kan silẹ. Melo ni o ni? Ẹ lee ka wọn lori ika mejeeji … ika ọwọ yin mejeeji, iye awọn ti Johannu fi fun Jesu Kristi nigbati Ó dé. Bibọ Rẹ lẹẹkeji nkọ? Ẹ ronu nipa rẹ.

Sugbọn nigbati awọn ti o gba Bibeli gbọ nitootọ ri Ọrọ naa ti a fi han ni gbangba fun iran yẹn, wọn gbagbọ. Ko si ọna lati mase jẹ ki wọn gba a gbọ. Wọn tilẹ fi ẹjẹ ara wọn se edidi ẹri wọn. Wọn gba a gbọ. Nigbanaa, o jẹ…. Awọn ni o wa fun, awọn ẹni iyantẹlẹ fun iran yẹn, awọn ni o ri i, ti wọn si gbagbọ.

39 Awọn tó kù kò tilẹ lee rii ni; a ti fọ wọn loju. Bayi, o sọ pe, “Wọn ko lee ri i kẹ.” Bayi, bii Balaamu, kini se ti Balaamu ko lee ri iyẹn? Wolii ni, ẹni-ami-ororo. Kini se ti Farao ko ri i? Nigbati o ri ọwọ Ọlọrun ti o sọkalẹ wa ti o si se isẹ-iyanu, o kan tun mu ọkan rẹ̀ le si i ni. Se bẹẹni? Ki lo de ti Datani ko lee ri i, ọmọ Juu funra rẹ̀? Ni gbangba nibẹ, o ti la Okun Pupa kọja, o si n jẹ manna ni alaalẹ́, ti o n sọkalẹ ni ọ̀tun, sibẹ ko lee ri i. Kini se ti Korah ko ri i? Kini se ti Kaiafa ko ri i? Oun ni olori ẹlẹsin agbaye ni akoko yẹn. Kini se ti ko fi rii wipe Messiah niyẹn? Kini se ti Judasi ko ri i? Judasi wa pẹlu wọn, o n ba wọn rin, o n se isẹ-iyanu pẹlu wọn. Sugbọn a nilati mu Ọrọ naa sẹ. Bibeli sọ wipe a gbé wọn dide ki wọn lee gba ipò yẹn ni. Idi ti a fi gbe wọn dide niyẹn. Otitọ ni. Iwe Roomu 8 sọ bẹẹ.

40 Bayi, awọn onigbagbọ lee ri Ọrọ naa ti o di ara ni iran tiwọn, Ọlọrun n sọrọ. Bayi, awọn onigbagbọ tootọ

yẹn, awọn ẹgbẹrun meje…. Abi ẹẹdẹgbẹrin ni, ni ọjọ Elijah? Ẹgbẹrun meje ni. Ni ọjọ Elijah, ẹgbẹrun meje eniyan ni o wà, ninu awọn bii miliọnu meji tabi mẹta, ti o ri i wipe otitọ niyẹn. Kò tilẹ tó ìdá kan ninu ìdá ọgọrun awọn eniyan naa. Sugbọn wọn ri i wipe o tọna. Wọn ri i ti Ọlọrun farahan. Obinrin opó nni ti a ran Elijah sí, o lọ wá awọn igi wọnyẹn, lati fi se akara, eyiti o to lati se akara fun oun ati ọmọdekunrin rẹ, ki wọn sì kú. Sugbọn ẹ wo Elijah; o ni, "Tete kọ se ọkan fun mi na. Nitori bayi ni Oluwa wi, 'ikoko iyẹfun naa ki yoo sofo, bẹẹni kólòbó ororo ki yoo gbẹ, titi di ọjọ ti Oluwa yoo rọ òjò sori ilẹ." Ko jiyan, o lọ taara lati se akara naa ki o si fi fun-un. O ni, "Tete kọ se temi na, lẹyinnaa ki o lọ se fun iwọ ati ọmọ rẹ." Nitori o gbọ ọkunrin yẹn, o si wo o, o jẹ iru ti a ti yan tẹlẹ.

41 Ọpọlọpọ wọn ni o sọ pe, "Okunrin asiwere yẹn tun ti de. Ọlọrun n fi wa bú nitori tirẹ." Ẹ ranti, Elijah sọ pe, "Iwọ gan-an ni o n da Israẹli láàmú."

Ó ni, "Iwọ ni o n da Israẹli láàmú." Se ẹ ri ẹniti Ọlọrun … ọrọ ẹniti Ó fihan? Ọrọ ara Rẹ.

Bayi, Bibeli sọ wipe a gbé wọn dide fun idi yii, sugbọn nigbati … alaigbagbọ. Sugbọn bayi nigbati onigbaagbọ tootọ lee ri Ọrọ ọjọ naa ti o di ara, ti Ọlọrun n sọrọ nipasẹ ètè eniyan, ti Ó si n se ohun ti O sọ wipe Oun yoo se gan-an, o pari.

42 Bayi ẹ kiyesi awọn ti o kù. Ẹ mase kiyesi awọn àmì. Ti ẹ ba n wo awọn àmì, a o tan yin jẹ dajudaju. Awọn wolii eke yoo dide, wọn o si fi isẹ-àmì ati isẹ-àrà han, to jẹ wipe yoo tan awọn ayanfẹ jẹ ti o ba see se. Ẹ maa wo Ọrọ yẹn. Ẹ wo awọn alufaa wọnyi, awọn wolii wọnyi, awọn wolii Heberu ti wọn duro sibẹ. Sedekiah pẹlu ìwo nla meji, ti o n wipe, "Mo jẹ wolii ti Ọlọrun yan." Otitọ ni. "Mo ni irinwo o din ẹyọkan pẹlu mi nibi, Ẹmi Mimọ si ba le wa, o n fihan, o si n sọ wipe ilẹ yẹn, tiwa ni. Ẹ jẹ ki a goke lọ, ki a lọ gba a. Ati pe nipa awọn ìwo wọnyi, Ahabu, iwọ yoo ti awọn ọta kuro lori ilẹ wa, nitori Ọlọrun ni o fun wa ni ilẹ naa."

43 Ẹ wo ọkunrin ẹlẹ̀sìn yẹn, eniyan rere, Jehosafati, wipe, "Se ẹ ko ni ọkan sii ni?"

"Ọkan sii kẹ? Awọn irinwo ni o fohùn sọ̀kan!" O ni, "Bẹẹni, ọkan tun wa si i ni itosi, sugbọn mo korira rẹ." O ni, igbagbogbo ni o maa n ba gbogbo wa wi, o maa n sọ wipe ẹlẹsẹ nla ni wa, ati ohun gbogbo bẹẹ. Mo korira rẹ. Mikaiah ni, omo Imla."

O ni, "Ah, mase jẹ ki ọba sọ bẹẹ. Ẹ lo pee, ki a gbọ ohun ti yoo sọ."

Wọn si mu u sọkalẹ wa sihin. O ni, "Ẹ fun mi ni alẹ oni, n o si mọ ohun ti Oluwa sọ nipa rẹ."

Ahabu sọ wipe, "Mo rọ ọ, mase sọ ohunkohun fun mi bikose otitọ."

Okunrin naa si wa, o sọ pe, "Bayi, ti o ba fẹ pada sinu idapọ daradara, sọ ohun ti awọn ti o kù sọ."

Mikaiah sọ pe, "Ohun ti Ọlọrun ba sọ ni n o sọ."

Ni owurọ ọjọ keji, wọn jade wa. Awọn ọba si wọ asọ igunwa wọn, wọn joko ni ẹnu ibode, ati gbogbo awọn ọ̀tọ̀kùlú. Awọn wolii naa duro sibẹ, wọn ni, "Bayi, iwọ gba-were-mẹsin, kini o sọ nipa rẹ̀?"

O ni, "Goke lọ." O ni, "Sugbọn mo ri Israẹli tuka bi aguntan ti ko ni olusọ."

44 O mu ọwọ rẹ o si gba a lẹnu. Wolii gba wolii lẹnu. Ni bayi, awọn wolii mejeeji ti o ni ami-ororo lo nsọtẹlẹ, awọn irinwo tako ẹnikan, eleyi dabi ẹni wipe o le. Ni bayi, kii se gbogbo igba ni aabo wa ninu ọpọlọpọ imọran. O da lori ibi ti wọn … ohun ti wọn n gba imọran nipa rẹ, ati ohun ti imọran wọn jẹ. Ko si aabo nibẹ fun ọba yẹn, o si gba ti ọpọ èrò yẹn wipe imọran tiwọn lo tọ́. Sugbọn iba se wipe o duro, ki o si akọsilẹ isọtẹlẹ ori awọ yẹn wò, ki o ri ohun ti Elijah ti sọ.

45 Nigbayẹn, Mikaiah ko lee sọ ohun kan; ko mọ boya Ọlọrun ti dari ji i fun-un. Sugbọn saaju na, nitori o jẹ wolii, o tọ Ọlọrun lọ lati wadi ohun ti Ọlọrun sọ. O si ri ohun ti Ọlọrun sọ. O ni, "Mo ri Ọlọrun joko lori itẹ, O si wipe… O ko gbogbo awọn igbimọ Rẹ ni ọrun yi ara Rẹ ka, O wipe, "Tani a le ri ran sọkalẹ lọ lati mu ki Ahabu jade wa sihin, ki a baa le mu asọtẹlẹ ti a ti sọ nipa rẹ̀ sẹ?"

Se ẹ rii, asọtẹlẹ, Elijah ti sọ tẹlẹ wipe, "Awọn aja yoo la ẹjẹ rẹ."

Nitorinaa o sọ wipe oun ri ẹmi irọ kan goke lati isalẹ, o goke wa, o goke wa siwaju Rẹ̀, o wipe, "Emi yoo sọkalẹ lọ wọ inu awọn wolii rẹ, awọn wolii Ahabu, n o si mu wọn sọ asọtẹlẹ irọ."

46 Bayi, Ọlọrun mọ wipe awọn ọkunrin yẹn gberaga, wọn si kun fun ẹko ẹsin to bẹẹ ti wọn ro wipe awọn ni ohun gbogbo ni ọna ti o tọ. Wọn ko fi igba kan kiyesi Ọrọ wakati naa. Nitorinaa, Ọlọrun sọ pe, "Iwo yoo se aseyọri, sọkalẹ lọ." Nigbati Mikaiah si sọ eleyi, iyẹn mu ki wọn maa sọ asọtẹlẹ labẹ ẹmi esu. Boya wọn ti fa okun tẹlifoonu yọ tabi ki wọn pa redio, tabi ki wọn se ohun miiran, nigbati wọn gbọ ọrọ yẹn ti o tako wọn, wọn

dide, wọn si jade lọ. Sugbọn ẹ wo ohun ti o sẹlẹ. Bayi, Mikaiah nilati yẹ iran rẹ̀ wo pẹlu Ọrọ ti a ti kọ silẹ, nitorinaa, ó mọ̀.

O ni, “Nigbati mo ba de…. Ẹ fi ọkunrin yẹn sẹwọn, ẹ fun-un ni omi ipọnju ati ounjẹ ipọnju. Nigbati mo ba pada de, n o yanju ọrọ rẹ.”

O ni, “Ti o ba pada rara, a jẹ wipe Ọlọrun kò ba mi sọrọ.” Igba yẹn ni o mọ wipe iran oun ba gbogbo ọrọ àkókò yẹn mu gan-an. Àkókò Ahabu ti tó.

Arakunrin, arabinrin, akoko ati wakati niyi fun pipe jade kuro ni Babiloni. Awọn imọlẹ asalẹ ti de. Ẹ maa rin ninu ẹmi nigbati imọlẹ si wa. Ẹ kiyesii, awọn onigbagbọ ri Ọrọ naa ti a fi han, wọn si gba A gbọ. Jesu wipe, “Awọn aguntan Mi mọ ohun Mi, Ọrọ Mi, awọn àmì Mi fun iran naa. Wọn ko ni tẹle ẹni èké.”

47 Bayi ẹ jẹ ki a lọ sinu koko ọrọ wa, nitori mo ri i wipe mo ti fẹ yago kuro ninu rẹ; mo fẹ tẹnu mọ ila adura yẹn pupọ. Ẹ jẹ ki a pada si koko ọrọ ti a n yẹwo bayi, fun isẹju diẹ. O dara, yoo tun sẹlẹ lẹẹkansii bi o se maa n se, bi o se maa n ri.

Ọlọrun ran wolii Rẹ̀, Johannu, gẹgẹbi Ọrọ Rẹ se sọ, ti a seleri ni Malaki 3, “Kiyesii, mo ran ojisẹ mi saaju mi, lati pese ọna silẹ.” Johannu jẹri nkan kannaa. A si tun rii pẹlu, ni Isaiah 40:3, wipe Isaiah sọ pe, “Ohun wolii kan yoo wa, ẹnikan ti n kigbe ni aginju, 'Ẹ pese ọna Oluwa silẹ.'” Gbogbo awọn asọtẹlẹ wọnyẹn! Ẹ si wo o, ẹ kiyesii kiakia bayi, Iwe Mimọ fi I han.

Nigbati wọn sọ wipe, “Ta ni iwọ? Se iwọ ni Messiah?

O ni, “Emi kọ.”

“Se iwọ ni Jeremiah? Awọn wolii, tabi ọkan ninu wọn?”

O ni, “Emi kọ. Sugbọn emi ni ohun ẹni ti n kigbe ni ijù, gẹgẹbi wolii Isaiah se sọ.”

Se ẹ ro wipe wọn yoo gba iyẹn gbọ? Rara, sa. Kini idi? Ko gba inu ijọ wọn wa. Ko si lara tiwọn…. Se ẹ rii, o lọ sinu aginju ni ọmọ ọdun mẹsan, o si jade ni ọmọ ọgbọn ọdun. Isẹ-iransẹ iwaasu rẹ se pataki ju wipe ki o lọ si ilẹ-ẹkọ ẹsin; oun ni o nilati fi Messiah han. Gbogbo awọn eniyan ni yoo si maa faa sihin ati sọhun. Ọlọrun si ran-an lọ sinu aginju lẹyin iku baba rẹ, Sakariah. Oun jẹ alufa, sugbọn ko tẹle ilana baba rẹ.

Nitori awọn wolii kii jade wa lati iru nkan bẹyẹn. Wọn maa n jade wa lati ibi ti o yigbi, ninu aginju. Ko si ẹniti o mọ ibi ti wọn ti n jade wa tabi bi wọn se bọ soju agbo, tabi ohunkohun nipa itan wọn. Wọn kan saa maa n jade wa, wọn o si waasu Ọrọ naa, Ọlọrun a si mu wọn kuro, wọn o si lọ; wọn o da iran yẹn lẹbi, wọn o si lọ sinu Ọrọ Rẹ, wọn o maa duro de ọjọ nla nni.

48 Ijọ ko gba a gbọ, nitori wọn ko mọ ọ́. Wọn ko ni akọsilẹ ifinisisẹ rẹ ninu iwe wọn, nitorinaa, wọn kọ ọ. Se ẹ rii, wọn kò gba Ọrọ Ọlọrun ti a fihan kedere gbọ, ni sisẹ ntẹle ọrọ. Se ẹ rii? Malaki 3, iwe mimọ meji lati fi i han, Malaki 3 ati Isaiah 40:3. Ẹẹ rii, awọn Iwe Mimọ mejeeji yẹn sọ nipa ọkunrin kan ti o n bọ, ti yoo pese ọna Oluwa silẹ. O ba gbogbo apejuwe rẹ mu.

O nilati jẹ wolii. “Emi yoo ran Elijah si yin.” Oun si niyẹn, ni gbogbo ọna ti o yi. Ẹ wo bi iwa-ẹda rẹ se ba ti Elijah mu. Elijah jẹ ẹni aginju, bẹẹ naa ni Johannu, ara aginju. Kii se ọlaju kan; ara oko kan ni.

Ẹ tun kiyesii, Elijah jẹ ẹniti o korira obinrin; o sọ fun Jesebeli nipa gbogbo ọ̀dà ti o n kùn, ati ibi ti o yẹ ki o rìn sí. Bẹẹ naa ni Johannu. Jesebeli gbiyanju lati pa Elijah, o fi awọn orisa rẹ bura wipe oun yoo mu ori rẹ kuro lọrun rẹ. Bẹẹ naa ni Hẹrodia, se ẹ rii.

Ẹ maa kiyesi isẹ-ohun-Ọlọrun ti wọn n jẹ, ẹ wo ohun ti wọn se. A rii bayi wipe, iba se wipe wọn wo ẹyin wo, ki wọn si ri ohun ti Bibeli sọ, ki wọn si wo iwa ẹda ọkunrin naa bi o se pe to ni àkókò pẹlu Iwe Mimọ ati gbogbo rẹ, o yẹ ki wọn ti mọ wipe oun ni. Awọn bii mẹfa pere ni o mọ ọ. Bẹẹ ni. Awọn ti o mọ ọ ko ju mẹfa lọ. Wọn lọ gbọ tirẹ, sugbọn wọn kò gba a gbọ, ẹẹ rii. Eese? Wọn kò gba idanimọ isọtẹlẹ ti àkókò wọn gbọ.

49 Ẹ kiyesii, wọn fi rẹrin, wọn pe e ni alariwo, ara oko, alailẹkọ, gba-were-mẹsin ti ko kawe, “lu, ko ri bẹẹ, gbé, mú, fẹ,” ati bẹẹ bẹẹ lọ. Bi o se maa n ri, wọn se odiwọn rẹ nipa iwe ti ó kà. Wọn se odiwọn rẹ nipa ede oyinbo ti o n sọ, nipa bi o se mura. O fi awọ aguntan bora, ati okun sokoto ti a fi awọ rakunmi se; irun bo gbogbo ara rẹ. O rin jade lati inu omi; ko ni ijọ, ko ni pẹpẹ iwaasu, ko ni ifọwọsọwọpọ kankan. Wọn kò lee gba iyẹn. Awọn n sin ọlọrun aye, se ẹ rii.

N ko sọ wipe ko si wolii eke ti o jade bayi, bii Jannesi ati Jambresi. Sugbọn bi ẹ se fẹ se ni wipe, ki ẹ yẹ ojulowo isẹ-ohun Ọlọrun naa wo pẹlu Ọrọ naa, nigbanaa yoo ye yin; iran wo ni o wa, ati kini ohun ti a sọtẹlẹ fun iran yẹn.

50 Nigbayẹn, asọtẹlẹ Johannu ni a fihan nipa àlàkalẹ̀ eto ti Ọlọrun. Ẹ wo bi o se pe to. Bibeli wipe, “Ọrọ Oluwa maa n tọ wolii wa.” Jesu si ni Ọrọ naa. Johannu si n sọtẹlẹ nipa wiwa Ọrọ naa fun imusẹ, Jesu tii se Ọrọ naa si tọ wolii naa wa ninu omi. Ah, eyi dara pupọ. O ti je alai lee kuna to…. Se ẹ rii? Ọrọ jẹ ohun ti o sọwọn ni igba yẹn. Wolii naa niyi, o n sọ pe, “Emi ni ohun Ọrọ naa.”

Wọn ni, “Kini a gbọdọ se?”

O ni, “Emi ko yẹ lati tu bata Rẹ. Sugbọn ẹnikan duro si aarin yin, nibikan, Oun ni yoo baptisi yin pẹlu Ẹmi Mimọ ati ina. Atẹ Rẹ n bẹ ni ọwọ Rẹ, yoo si gba ilẹ ipaka Rẹ mọ́, yoo si fi ina àjóòkú sun awọn epo, yoo si ko alikama si àká.” Ah, iru wolii wo niyẹn! Jesu wipe ko si ẹniti a tii bi nipasẹ obinrin ti o jẹ ẹni nla bii tirẹ, titi di ọjọ yẹn. Ah, eleyi lagbara! O mọ ibiti oun wa! O mọ gan-an ni. O ti gbọ lati ọdọ Ọlọrun, o si ba Ọrọ naa mu gẹgẹ, nitorinaa ko bikita ohun ti awọn eniyan sọ. O waasu rẹ, o si sọtẹlẹ nipa rẹ bakannaa. Ẹ si kiyesii, nigbati ẹnikan ba duro lori ohun tii se otitọ, nigbanaa o di dandan gbọn fun Ọlọrun lati fi ẹni yẹn han wipe o jẹ otitọ.

51 Nigbati Mose sọkalẹ lọ si Egipti, ti o wipe, “Mo wa ninu aginju nibẹyẹn, mo si ri igi kan ti o gbina, sugbọn ko parun. Mo lọ si ibi igi naa, nigbati mo si se bẹẹ, ọwọn ina nla kan wa nibẹ, ti o sorọ̀. Ohun kan si wipe, 'EMI NI ẸNITI N JẸ EMI NI.' O si sọ fun mi wipe ki n mu ọpa yii, ki n si wa sihin ki n se awọn isẹ-iyanu wọnyi, wipe Ọlọrun yoo si fi idi Ọrọ Rẹ mulẹ.” O na ọpa naa sita, awọn kokoro ati awọn esinsin si jade wa, ati okunkun, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Lati wa fi wolii yẹn han, O mu awọn onigbagbọ yẹn pada wa si ori oke naa, Ọlọrun si sọkalẹ ninu ọwọn ina kannaa, lori oke yẹn gan-an, O si fihan wipe otitọ niyẹn.

Bayi ẹ wo ohun ti O ti se ni iran yii. Bẹẹ gan-an ni.

52 Bayi, Ọrọ naa tọ wolii wa, o si fihan wipe oun ni ẹni tootọ, ẹni naa gan-an ti Iwe Mimọ sọ wipe yo jẹ. Ni kiakia bayi. Sugbọn, lẹẹkansii, Jesu wá ni ìrí miiran yatọ si itumọ eniyan ti awọn fun asọtẹlẹ naa. Eniyan ti tumọ ohun ti yoo jẹ. Dajudaju. Awọn ijọ Alagba ro wipe o yẹ ki o jẹ awọn. Ẹ kiyesii nigbati Ọlọrun ba se ohunkohun, ẹ wo gbogbo awọn ijọ ti a fi ọgbọn eniyan gbe kalẹ yoo dide pẹlu tiwọn naa. Bẹẹni, bẹẹni, bi o se maa n ri niyẹn. Wọn ni awọn Jannesi ati Jambresi kaakiri. Ẹ kiyesii, wọn sọ apakan Ọrọ naa. Sugbọn, ni ibamu pẹlu ọrọ wolii naa, gbogbo ọrọ!

53 Wọn tun kuna rẹ, bii ti tẹlẹ, wọn pe E ni alafọsẹ, èsù, Bélsébúúbù, wọn ni o sọ ara Rẹ di Ọlọrun, nigbati o yẹ ki wọn mọ nipa Bibeli wọn wipe Oun ni Ọlọrun. Ẹ kiyesii, a ti sọtẹlẹ nipa Rẹ lati ọwọ Isaiah, Isaiah 9:6, sọ pe, “A o pe orukọ Rẹ ni Ọlọrun Alagbara, Baba Ayeraye.” Ko lee si baba miiran mọ lẹyin iyẹn, nitori Oun ni Baba akọkọ ni atetekọse; Oun naa si ni Baba kansoso. O ni, “Ẹ mase pe ẹnikankan ni baba lori ilẹ aye, 'Baba', boya, lẹyin iyẹn.” Oun ni Ọlọrun Alagbara, ati Baba Ayeraye, Oludamọran, Ọmọ Alade Alaafia. Dajudaju.

Bayi, wọn ti se gbogbo ohun ti awọn wolii ti sọ wipe wọn yoo se si I, gẹgẹbi wọn ti n se ni iran Laodikea yii, wọn ti I sita kuro ninu ijọ. “Wọn foju, wọn wa ni ihooho, wọn ko si mọ ọ.” Ohun ti wolii naa sọ, wolii Bibeli. Asa eniyan ti fọ wọn loju, wọn ti I sita, iyẹn Ọrọ naa, kuro ninu awọn ijọ wọn, bii ti tẹlẹ, ani bi a ti sọtẹlẹ nipa wọn.

54 Ẹ kiyesii ni kiakia bayi. Ẹ mase padanu eleyi. Koko ọrọ naa niyi, bi Jesu se fi ara Rẹ han fun awọn ọmọ ẹyin meji yii, wipe Oun ni Messiah wọn! Bayi, gbogbo yin ẹ kọ oju sibi. Ati ẹyin ti ẹ n gbọ wa kaakiri, ẹ mase padanu eleyi bayi. A ti gbiyanju lati sọ fun yin wipe Bibeli ni Ọrọ Ọlọrun, ti Ọlọrun kọ funra Rẹ, nipa ètè ati ohun èlò awọn eniyan. Ọlọrun lee kọwe funra Rẹ. Ọlọrun lee sọrọ funra Rẹ. Ọlọrun lee se ohun ti O ba n fe lati se, sugbọn O yan awọn eniyan lati se e, nitori awọn eniyan ti o kọ Ọ jẹ ara Ọlọrun. Nitorinaa, Ọlọrun ni o kọ Bibeli. Awọn okunrin yẹn ko tilẹ mọ ohun ti wọn n kọ, ninu èrò tiwọn bi eniyan. O see se ki wọn tako o, sugbọn wọn saa kọ ọ. Wọn ko lee se bẹẹ. Bibeli wipe, “Awọn ẹni igba atijọ nkọ, bi a ti n dari wọn lati ọwọ Ẹmi Mimọ….” Ọlọrun lo ọwọ wọn, O lo oju wọn ninu awọn iran. Wọn ko lee sọ ohunkohun bikose ohun ti wọn n wo. Wọn ko lee sọ ohunkohun, nitori Oun ni o n sakoso ahọn ati ìka wọn lẹkunrẹrẹ; gbogbo ẹ̀yà ara wọn ni o wà ni isọkan patapata pẹlu Ọlọrun. Abajọ ti Bibeli fi sọ wipe wọn jẹ ọlọrun; wọn jẹ apakan ara Ọlọrun. Oun ni ẹkunrẹrẹ Ọlọrun.

55 Ẹ kiyesi bi Jesu, Ọrọ naa, se mu ki awọn ọmọ ẹyin meji tí inu wọn bajẹ yii mọ wipe Oun ni Messiah wọn, Messiah naa, Ọrọ naa ti a seleri. Ẹ kiyesi ohun ti o se: O pada sinu asọtẹlẹ. Ẹ kiyesii, “Ẹyin omugọ, ọlọkan yiyi lati gba ohun gbogbo ti awọn wolii ti kọ gbọ́.” Bayi, ko sọ wipe, “O dara, kini ijọ sọ nipa rẹ?”

Wọn sọ ohun ti o sẹlẹ fun-Un. Wọn mọ gbogbo isẹlẹ ti o sẹlẹ. Gbogbo wọn banujẹ. Wọn bẹrẹ si sọ fun-Un, “Se alejo ni Iwọ nihin ni, tabi O kò mọ ohun ti ó sẹlẹ ni Jerusalẹmu”

O ni, “Awọn kini?” - bi ẹni wipe kò mọ. Se ẹ rii, O maa n se awọn nkankan nigbamiran, lati wo kini ẹ o se nipa rẹ. Se ẹ rii? “Awọn kini?” Tani ẹni naa? Ki lo sẹlẹ?“

"Se alejo ni Iwọ ni?" Wọn si n ba ọkunrin naa ti wọn ti ba gbe fun ọdun mẹta ati aabọ sọrọ, wọn kò sì mọ̀ Ọ́.

"Awọn kini? Ki lo sẹlẹ?"

O dara, wọn ni, "Jesu ti Nasarẹti, tii se Wolii. Ko si iyemeji ni ọkan wa, O jẹ alagbara ni ọrọ ati ise niwaju gbogbo eniyan. A ri I ti O se awọn nkan ti o fihan wipe Oun ni Wolii Ọlọrun fun iran yii. Awa mọ iyẹn. Awa si gbagbọ wipe Oun ni yoo jẹ Olurapada, wipe Oun ni yoo ra Israẹli pada."

Nigbanaa ni O yiju pada, ti o si wipe, "Ẹyin omugọ, ẹyin ọlọkan yiyi, lati gba ohun gbogbo ti awọn wolii ti sọ nipa Rẹ gbọ wipe yoo wa si imusẹ?" Ẹ kiyesi Oun. Ẹ pada si asọtẹlẹ bayi. Eyi jẹ ibawi fun awọn onigbagbọ, ti wọn sọ wipe awọn gba A gbọ.

56 Ẹ wo bi o se bẹrẹ ọrọ naa. Kò sọ jade gbangba wipe, "Emi ni Messiah yin." O lee se e, nitori Oun ni. Sugbọn ẹ kiyesii, O fi ara Rẹ han ninu Ọrọ, nigbanaa wọn yoo mọ̀. Iba se wipe O ti sọ ọ ni…. O see se ki O ti sọ iyẹn, ki o ma si ri bẹẹ; sugbọn nigbati o bẹrẹ si sọrọ nipa ohun gbogbo ti awọn wolii ti sọ nipa Rẹ, ti wọn si rii, nigbanaa wọn lee sọ fun ara wọn, ti wọn ba jẹ ọmọ Ọlọrun. Sugbọn O pe akiyesi wọn si ohun ti awọn wolii ti sọtẹlẹ ti wọn si sọ wipe ki wọn foju sọna fun ni igba ti Messiah, ti iran Rẹ yoo farahan. Oun, bii ti Johannu, jẹ ki Ọrọ naa, ani Bibeli, fi isẹ-iransẹ iwaasu wọn han. Gbogbo wolii tootọ ni yoo se bẹẹ. Bẹẹ ni. Ko sọ jade taara wipe, "Emi ni. Emi…." Iyẹn kii se wolii Ọlọrun tootọ, se ẹ rii. Sugbọn O sọ wipe, "Ẹ pada sinu Iwe Mimọ." Se ẹ rii, ko kuna bi O se maa n se e, se ẹ rii.

O ni, "Awa mọ Mose."

O ni, "Iba se pe ẹ mọ Mose ni, ẹ ba mọ Mi." O ni, Mose kọ nipa Mi." O ni, "Ẹ wa inu Iwe Mimọ; ninu wọn ni ẹ ro wipe ẹ ti ni iye ainipẹkun, awọn Iwe Mimọ ni o si n jẹri nipa Mi. Ẹ lọ wo inu Iwe Mimọ ki ẹ si ri i.

57 Nihin, ko yi ọna ti O n gba se e pada, ko si yii pada ri. Ko si lee yii pada, nitori Oun ni Ọlọrun ti kii yipada, se ẹ rii. Ẹ kiyesii, O pada tọ awọn ọmọ ẹyin meji wọnyi lọ, Kleopa ati ọrẹ rẹ, ni oju ọna Emmausi, O si wipe … tọka Iwe Mimọ si wọn, wipe, "Eese ti ẹ fi ya omugọ to bẹẹ, lati mase gbagbọ wipe gbogbo ọrọ ti awọn wolii kọ nipa Messiah ni a gbọdọ mu sẹ?" Ah, iru ọjọ wo niyẹn!

Johannu se nkan kannaa. "Ẹ wa inu Iwe Mimọ, ẹ wo ẹyin wo, o ni ohùn ẹnikan yoo maa kigbe ni aginju. Nibo ni mo ti wa?" O yẹ ki iyẹn jẹ ki o ye wọn kedere. Bẹẹ ni.

O yẹ ki o hàn kedere loni, ohun ti a ri ti Ẹmi Mimọ n se. O sọ nigba kan pe, "Ẹ wa inu Iwe Mimọ." O si fẹ ki a se e loni pẹlu.

58 Ẹ kiyesii, O bẹrẹ pẹlu asọtẹlẹ Mose, Bibeli wipe, "Oun bẹrẹ pẹlu Mose ati gbogbo awọn wolii," sugbọn O bẹrẹ pẹlu Mose. Mose wipe, "Wolii kan ni Oluwa Ọlọrun yin yoo gbe dide laarin ẹyin eniyan wọnyi, laarin awọn eniyan. Oluwa Ọlọrun yoo gbe wolii kan dide."

Bayi, O ti le sọ wipe, "Kleopa, iwọ ati ọrẹ rẹ nibi, njẹ Mose ko sọ wipe Oluwa Ọlọrun yoo gbe wolii kan dide ni awọn ọjọ wọnyi? Ati ọkunrin ti wọn kan mọ agbelebu yii, njẹ O ba amuyẹ naa mu? Bayi, Mose sọ asọtẹlẹ eleyi. Ẹ ko si tii ni wolii kankan fun ọgọọgọrun ọdun, ọkunrin yii si niyi ti o dide. Ta si ni ẹ sọ wipe o saaju bibọ ọkunrin yii?" Se o ye yin? Ati ohun gbogbo ti awọn wolii sọ nipa Rẹ, fun iran Rẹ, o sọ ọ fun wọn. Dajudaju, yoo jẹ ohun ti o dara lati feti si I. Njẹ ko ni wu yin lati gbọ Ọ? Emi yoo fe lati gbọ Ọ, lati gbọ Ọ, ohun ti O ni awọn wolii sọ nipa ara Rẹ, sugbọn ko fi igba kan sọ wipe Oun ni. O kan fi asọtẹlẹ han wọn ni. O kan sọ wipe, "Awọn wolii sọ wipe eleyi yo sẹlẹ," se ẹ rii.

59 Ẹ jẹ ki a pada sẹyin fun iseju diẹ, ki ẹ sì jẹ ki a feti si awọn ọrọ ti O sọ lati ọdọ ara Rẹ. Ẹ wo ibi, Ọrọ naa funra Rẹ, ti O n sọ Ọrọ ti ara Rẹ. Ọrọ naa funra Rẹ, ti O n sọ Ọrọ ti ara Rẹ. Ko sọ fun wọn wipe Oun ni ẹni yẹn, sugbọn O kàn jẹ ki Ọrọ na sọrọ funra rẹ, nigbanaa wọn mọ ẹni ti Ó jẹ. Akọsilẹ Ọrọ naa, ti o n sọ Ọrọ ni…. Ọrọ naa ninu ara, ti O n sọ Ọrọ naa ti a kọ silẹ, ti a fihan lẹkunrẹrẹ pẹlu ara Rẹ. Ẹ wo ibi, bayi ẹ jẹ ki a feti silẹ bi O se n sọ ọ. Bayi a mọ wipe gbogbo wọn ni a ti sọ fun nipa awọn isẹlẹ ti o sẹsẹ sẹlẹ laipẹ, iyẹn nipa kikan mọ agbelebu, ati ọrọ ajinde, ti iboji, bi a se sẹsẹ kà á. Bayi O lọ taara sinu Ọrọ asọtẹlẹ nipa ara Rẹ. Bayi ẹ jẹ ki a kàn ronu wipe O sọ eleyi; O sọ pupọ ju eleyi lọ, sugbọn ẹ kiyesii.

60 Ẹ jẹ ki a sọ wipe, a gbọ ti O sọ wipe, "Ẹ si Sekariah 11:12. Njẹ a ki yoo ta Messiah, gẹgẹbi wolii naa se sọ, fun ọgbọn owo idẹ wẹ́wẹ́? Ẹ sẹsẹ sọ wipe wọn ta ọkunrin yii fun ọgbọn owo idẹ wẹwẹ. Ẹ sí i." Se awọn iwe mimọ yẹn n ye yin? Sekariah 11:12. Lẹyinnaa O sọ wipe, "Njẹ ẹ kiyesi ohun ti Dafidi sọ ninu Orin Dafidi, Orin Dafidi 41:9? Awọn ọrẹ Rẹ yoo dà Á. Lẹyinnaa ẹ̀wẹ̀, ni Sekariah 13:7, awọn ọmọ ẹyin Rẹ kọ̀ Ọ́ silẹ. Ati ni Orin Dafidi 35:11, awọn ẹlẹri eke fi ẹ̀sùn kàn-Án. Ẹ sẹsẹ sọ tan ni wipe wọn se bẹẹ si I. Isaiah 53:7, O yadi niwaju awọn olùfisùn Rẹ̀. Isaiah 50:6, wọn nà Á, wolii naa sọ bẹẹ. Orin Dafidi 22, O nilati kigbe lori agbelebu, 'Ọlọrun Mi, Ọlọrun Mi, eese ti Iwọ fi kọ̀ Mí sílẹ̀?'" Se O se bẹyẹn, ni ọsan ijẹta? Ati Orin Dafidi 22 lẹẹkansii,

:18, wọn pin asọ Rẹ laarin ara wọn. Se wọn se bẹẹ? Ati Orin Dafidi 22:7 - 8, awọn ọta Rẹ fi I se ẹlẹya, iyẹn ijọ. Orin Dafidi 22 lẹẹkansii, a ki yoo fọ egungun kan ni ara Rẹ̀, sugbọn 'wọn gun mi ni ọwọ ati ẹsẹ,'

Ó sọ bẹẹ. Ko si iyemeji wipe O ka ọwọ Rẹ̀ si ẹyin Rẹ̀ nigba yẹn.“ Isaiah 53:12 sọ wipe yoo kú laarin awọn ọdaran. Isaiah 53:9 sọ wipe a sin pẹlu awọn ọlọrọ. Orin Dafidi 16:10 sọ wipe, 'Emi ki yoo fi ọkan Rẹ̀ silẹ ni ipo oku, bẹẹni Emi ki yoo jẹ ki Ẹni Mimọ Mi ri idibajẹ.' Njẹ Malaki 3 kọ ni asaaju ọkunrin yii” Ah, yoo wu mi lati gbọ ki O sọ iyẹn. Ẹ wo awọn asọtẹlẹ. Ẹ kiyesii, lẹyinnaa gbogbo awọn afiwe ti yoo ti sọ, nipa Isaaki, ni Gẹnẹsisi 22, bi Ọlọrun se fi Isaaki se ojiji, bi baba Abrahamu se mu ọmọkunrin rẹ, o gbe igi lọ sori oke, ti o si fi ọmọkunrin rẹ rubọ.

61 O sẹsẹ wa n ye wọn wayi. O ti sọ fun wọn wipe wọn jẹ omugọ, nitori wọn kò wo asọtẹlẹ fun ọjọ yẹn. Bayi, o wa sẹsẹ n ye wọn, wọn sẹsẹ n ri imusẹ ohun gbogbo ti o ti sẹlẹ ni ọjọ melo kan sẹyin, ni nikan bii ọdun meji si mẹta sẹyin, asọtẹlẹ ti a fihan fun iran naa. Igba yẹn ni wọn to mọ wipe ọrẹ wọn ti a kàn mọ agbelebu, Jesu, ti mu gbogbo ọrọ yii sẹ. Ah, igba yẹn ni wọn to mọ wipe, lootọ, ọkunrin yẹn ni Messiah, wipe O nilati jinde kuro ninu òkú. Iboji ko lee so Ó mọ́lẹ̀. “N ki yoo jẹ ki Ẹni Mimọ Mi ri idibajẹ.” Ko si ọkan ninu ọrọ asọtẹlẹ ti o lee kuna laelae. O si jinde.

62 “A jẹ wipe awọn ojisẹ ti o wa ni ibi iboji yẹn ni owurọ yii sọ otitọ. O ti jinde kuro ninu oku. O wà laaye. Oun ni Messiah naa.” Ki ni idi? Ẹ mase kuna rẹ. Ise Rẹ, isẹ-iriju iwaasu Rẹ ati ohun gbogbo ti O ti se ni a ti fi han gẹgẹ bi ọrọ ti awọn wolii ti sọ wipe yoo sẹlẹ fun ọjọ oni. O ti pari. Nigbanaa, wọn mọ wipe Oun ni, ọrẹ wọn ti a kan mọ agbelebu, Jesu, ni o se e. Abajọ ti ọkan wọn fi gbina jẹ ninu wọn nigbati O n ba wọn sọrọ. Bayi, wọn ti rin maili mẹfa, o si dabi àkókò kukuru.

63 Ohun miiran ti wọn tun se niyi, se ẹ mọ, wọn ti gbọ iwaasu wakati mẹfa nipa bi a se mu asọtẹlẹ sẹ. Ohun ti O ba wọn sọ loju ọna niyẹn. Kete ti wọn bọ soju ọna, O jade sita, nitori O wa ni Jerusalemu nibẹ. Lẹyin wakati mẹfa, ọgọta ibusọ, wọn wà loju ọna, maili mẹfa si Emmausi. Ohun ti o jẹ niyẹn. O si ti waasu, o fi idi asọtẹlẹ mulẹ fun wakati mẹfa. Ẹ mase da mi lẹbi lori wakati mẹta temi, se ẹ rii. Sugbọn ẹ kiyesii, wọn ti waasu…. Wọn ti gbọ iwaasu wakati mẹfa lori mimu asọtẹlẹ sẹ, ti a fi hàn.

64 Bayi, o ti n di ọwọ irọlẹ. Se ẹ mọ, ọkanaa ni Oun lana, loni, ati titi laelae. Igba yẹn ni O si wọn loju lati mọ wipe (Heberu 13:8) ọkanna ni Oun lana, loni, ati titi laelae. Ni àkókò asalẹ, a jẹ ki awọn isẹlẹ yé ni nipa asọtẹlẹ. Awọn nkan ti o n sẹlẹ lode oni ni a le da mọ pẹlu irọrun, ti ẹ ba saa lee gba asọtẹlẹ wakati yii gbọ.

“Bẹẹni, omugọ, ọlọkan yiyi, ti ọkan wọn yi lati gbagbọ (ẹyin ẹ maa ronu lee lori), lati gbagbọ wipe ohun gbogbo ti awọn wolii sọ nipa Messiah, se ko nii sẹlẹ ni?” Bayi, Ó yẹ awọn kókó wọnyi wọ lọ sẹyin, O si fi awọn nkan ti wolii sọ wipe yoo sẹlẹ han. Nigbanaa ni o to bẹrẹ si ye wọn. O wa sọ wipe … se bi ẹni wipe Oun yoo kọja wọn lọ. Wọn fẹran ọkunrin yii. Wọn ni, “O ti fun wa ni nkankan. A ko fi igba kan ronu iyẹn. O wa laaye nibikan.” Oun ni wọn n ba sọrọ, wọn kò si mọ. Nitorinaa, Ó wò wọ́n pẹlu ibanujẹ, Ó sì bẹrẹ si kọja lọ, sugbọn O n duro de wọn wipe ki wọn pe Oun. Ohun ti O n duro de ni asalẹ yii niyẹn, wipe ki o pe Oun.

65 Ẹ si kiyesii, nigbati awọn ọmọ ẹyin yẹn pe E sibi idapọ wọn nibi tabili, igba yẹn ni o wa se nkankan ti O se ni kete saaju kikan mọ agbelebu Rẹ, oju wọn si là. Wọn mọ iwa Rẹ, isesi Rẹ. Wọn mọ ohun ti O ti se, O si se e nigba yẹn, gẹgẹbi O ti se tẹlẹ. Wọn si wipe, “Oun niyẹn!” Kiakia wọn dide lati pariwo sita, O si poora. Ibiti wọn ti fi wakati mẹfa gbọ iwaasu yii, boya ogun isẹju ni wọn fi sare pada lati sọ fun awọn ti o kù, “O ti jinde nitootọ. Lootọ ni O wà laaye.”

66 Ẹyin ọre, eyi ni imusẹ Malaki 4, Luuku Mimọ 17, Johannu Mimọ 15, ani, ọpọlọpọ, Ifihan 10, ọpọlọpọ asọtẹlẹ ti a le so pọ mọ ọjọ oni. Ati pẹlu ninu iwe Maaku ati Matteu, nibiti O ti sọ wipe awọn ami ati iyanu nla yii yo farahan ni oju ọrun, awọn eniyan si n pè wọ́n ni àwo, awọn àwo ti o n fò, ti wọn si le fi agbara poora ni kiakia, bi èrò ọkan lasan, awọn ọgbọn ti o le wọle wa. O lee kọwe, O lee sọrọ, O lee se ohunkohun ti O ba fẹẹ se. Ọwọn ina nla naa, ọkannaa lana, loni, ati titi laelae. Ati awọn nkan ti a le foju ri ti o n wa sori ilẹ aye, awọn ile olori sonso, eefin ti o ngoke lọ sinu afẹfẹ, kọja ibi ti ìkúùku lee wà tabi ohunkohun, ọgbọn maili soke. Ti a ti sọtẹlẹ ni ọdun kan ati aabọ ki o to sẹlẹ, wipe yoo ri bẹyẹn. Ẹ yii aworan naa ki ẹ si wo ẹniti o n wo isalẹ. Ko si ọkankan ninu ọrọ ti a sọ ti o kuna ri, Ọrọ Ọlọrun ti a kọ silẹ niyi, ti o n fi idi re mulẹ pe otitọ ni. A tun ti wà ni wakati asalẹ lẹẹkansii. N ko mọ boya yoo pada wa, pẹlu oore-ofẹ, ni asalẹ yii, ki O si se nkankan bi O se se nibẹyẹn. Ẹ jẹ ki a gbadura, ki a si beere lọwọ Rẹ. Awọn isẹlẹ ni a mu ki o ye ni nipa asọtẹlẹ ti a fihan.

67 Ọlọrun Olodumare, ran wa lọwọ. Ran wa lọwọ, Ọlọrun ọwọn, lati loye, lati loye awọn nkan ti o yẹ ki a mọ, lati loye Ọrọ Rẹ. Ni bayi, Oluwa, a ti gbọ awọn iwaasu fun bii ẹgbaa ọdun, ati kikọ awọn iwe. Ni ikẹyin ọjọ yii pẹlu, o tun ti pada wa, o si ti n di ọwọ asalẹ bayi. Awọn ijọ Eleto, Onitẹbọmi, Alagba, ati ọpọlọpọ wọn ni gbogbo iran ti ba Ọ sọrọ, boya ni oju ọna ọjọ nla yi ti kò jẹ òru tabi ọ̀sán, bi wolii naa se sọ, sugbọn ni ọwọ asalẹ, imọlẹ yoo wà. Jesu ji dide kuro ninu iboji, O si fara han Simoni ati awọn obinrin, O si fi han wọn wipe Oun wa laaye. Owurọ niyẹn. Lẹyinnaa, ni asalẹ O tun pada wa. Sugbọn O n ba wọn sọrọ loju ọna, o n ba wọn wi fun ifọju wọn, sugbọn O fi ara Rẹ han fun wọn ni akoko asalẹ.

68 Ọlọrun, wa si aarin idapọ wa ni asalẹ yii, eyi ti a ni yika Ọrọ naa. Ọlọrun, o sọwọn lati gbagbọ laarin awọn eniyan loni, sugbọn mo dupẹ wipe awọn kan wa ti O ti pe, ti O si ti yan tẹlẹ si iye ainipẹkun, O si wipe, “Gbogbo awọn ti Baba ti fi fun Mi ni yoo wa.” Ni bayi, nigbati awọn imọlẹ asalẹ n tàn, Oluwa, nigbati O ti fi aaye gba a, wipe ko si asọtẹlẹ ẹyọ kan (ninu ọgọọgọrun ti o ti jade lọ) ti o kuna nigba kan ri. Njẹ ti eleyi ba se afihan, o nilati jẹ Iwọ, nitori ko si eniyan kankan ti o lee pe bẹẹ. Gẹgẹbi bii Bibeli, ko si ẹni ti o lee kọwe, ko si ẹnikan laarin ẹgbẹjọ ọdun, lati ọwọ ogoji onkọwe ọtọọto, ti o lee kowe, ti ko si ni si asise kankan nibẹ. Ọlọrun ọwọn, mo gbadura wipe ki O fi ara Rẹ han ni asalẹ yii, ti Heberu 13:8, wipe okanna ni Ọ lana, loni, ati titi laelae. Awọn isẹ ti O si se nigbanaa, oun naa ni O n se loni. O si se ileri rẹ; O sọ pe, “Ni ikẹyin ọjọ wọnyi, nigbati aye ba wa ni ipo Sodomu ati Gomora, idibajẹ.” A n ri awọn ọmọkunrin wọnyi ti wọn da bii obinrin gan-an, wọn n wọ asọ bii tiwọn, a si ri awọn ọmọbinrin n gbiyanju lati se bii ọmọkunrin, a si ri awọn obinrin ati awọn ọkunrin ni iran ti o dibajẹ yii, ti wọn n wa oju awọn ọkunrin mọra lati sọ ara wọn di orisa àkúnlẹ̀bọ. Wọn ti gbá Ihinrere si ẹgbẹ kan, ati ihooho ni ijọ Laodikea. Ọlọrun o, iru wakati wo niyi! Jesu Oluwa, maa bọ, fi ara Rẹ han fun wa. Nitori a beere ni orukọ Jesu.

69 Bayi bi ẹ se tẹriba ti ẹ si di oju yin, n ó beere ohun kan lọwọ yin. Se ẹ gbagbọ wipe Ọlọrun wa nihin? Se ẹ gbagbọ wipe awọn nkan ti o n se loni jẹ imusẹ asọtẹlẹ? Se ẹ gbagbọ wipe Jesu Kristi jẹ ọkannaa lana, loni, ati titi laelae? Se ẹ gbagbọ wipe nigbati O wa nibi, ti O fi ara Rẹ han ninu ara fun ọjọ yẹn, ati awọn isẹ ti O se nibẹ, yoo tun pada sẹlẹ ni ọjọ oni? Wolii naa sọ bẹẹ. Bibeli sọ bẹẹ. Gbogbo Iwe Mimọ ni a gbọdọ mu sẹ; ko lee kuna. Bawo ni O se fi ara Rẹ han? Nipa jijẹ wolii naa ti Mose sọ nipa re. O mọ asiiri ọkan awọn eniyan. Obinrin yẹn fi ọwọ kan iseti asọ Rẹ; O yipada O si wipe, “Igbagbọ re ti gba ọ la.” Nigbati Simoni Peteru wa si ọdọ Rẹ, O mọ orukọ rẹ, O sọ ẹni ti o jẹ fun-n, ati ẹni ti baba rẹ̀ jẹ. Jesu olufe yẹn kannaa kò kú, Ó wà laaye titi laelae. Iyin ni fun Ọlọrun! Mo si gbagbọ, ni akoko asalẹ yii bayi, O tun ti pè wá jọ papọ.

70 Jesu Oluwa, wa si aarin wa. Mase re wa kọja. Wa, duro ti wa ni gbogbo oru, titi ti oru yii yoo fi kọja, lẹyinnaa jẹ ki a lọ pẹlu Rẹ ni ọla, ki a lee mọ̀ Ọ́ ninu agbara ajinde Rẹ, ki ifẹ, oore-ofẹ ati aanu Rẹ lee wà pẹlu wa. Ọlọrun ainipẹkun, se awọn nkan wọnyi. A mọ wipe Ọlọrun nikan ni o lee se wọn bẹẹ.

Ni akoko ironujinlẹ yii, ẹ jẹ ki a sọ bayi: Ọlọrun Baba wa, ara wa jẹ agọ ti kò yẹ fun Ọ. Sugbọn, Oluwa, jẹ ki oore-ofẹ Rẹ ti o n sọ ni di mímọ́, Ẹmi Mimọ Rẹ, wa bayi. Wẹ wa mọ kuro ninu iyemeji ati idalojuru, gbogbo ifura ati iyemeji ti o lee wa ninu wa, ki a le ni ominira laini iyemeji kankan; ki a jade wa, ki a si jẹwọ pẹlu igboya bii Peteru, wipe, “Iwọ ni Kristi naa, ọkannaa lana, loni, ati titi laelae.”

71 A gbagbọ wipe otitọ ni Ọrọ Rẹ, Oluwa. Saa jẹ ki a rii, ki a to bẹrẹ ila adura yii, Oluwa, ki O si fi ara Rẹ han fun wa. Ati gẹgẹ bi O se sọ, bi o se ri ni ọjọ Lọọti. Nigbati Abrahamu, ẹgbẹ ti a pè jade nni, ti o n duro de ọmọ ti a seleri, Lọọti wa nibẹyẹn, o n gbọ Billy Graham ati Oral Roberts ti ode oni, si awọn ijọ ẹlẹkọ adamọ ti wọn gbe kalẹ sibẹyẹn, gẹgẹbi orilẹ-ede. Sugbọn Abrahamu jẹ atipo laini igbekalẹ eniyan kankan, yatọ si awọn ẹgbẹ kekere yii ti o kàn n rin kiri lori ilẹ ti oun yoo pada wa jogun rẹ. “Awọn onirẹlẹ ni yoo si jogun aye.” Lọjọ kan, labẹ ojiji igi, nigbati wọn joko, ti wọn n simi, Ọlọrun sọkalẹ ni ìrí eniyan. Awọn angẹli meji lọ si Sodomu. Ọlọrun, ninu ara eniyan, fihan wipe Oun ni. O ni, “Abrahamu, Sarah, iyawo rẹ da?” Ọjọ melo kan saaju asiko yẹn, o jẹ Abramu, ati S-a-r-r-a, Sarra; kii se Sarah, “ọmọbinrin ọba.” O si fi orukọ rẹ̀ gẹgẹbi ọmọbinrin ọba pe e, ọmọbinrin ọba kan. O pe Abrahamu nipa orukọ rẹ̀, Abrahamu, baba orilẹ-ede pupọ. O si wipe, “Emi yoo bẹ yin wo.”

72 Ọlọrun, aya wolii yẹn yoo ti ja. Ó mọ ẹniti O jẹ kiakia. Abajọ ti o fi wẹ ẹsẹ Rẹ, ti o si gbe gbogbo ounjẹ ti o ni jade, eyiti o dara julọ, o si gbe e si iwaju Rẹ. O mọ wipe Ọlọrun ni o wà nibẹyẹn. Nigbannaa Ó sọ wipe “Nibo ni Sarah wa?” bi ẹni wipe kò mọ.

Abrahamu si wi fun-Un pe, “Ó wà ninu àgọ́ … ó wà ninu àgọ́ lẹyin Rẹ.”

O si sọ wipe ohun ti yoo sẹlẹ. Oun, ninu ọkan rẹ, si siyemeji rẹ. Nigbanaa ni O wi fun Abrahamu pe, “Eese ti Sarah siyemeji iyẹn, ti o sọ ninu ọkan rẹ wipe, 'Nkan wọnyi ko lee ri bẹẹ'? Ohun kan ha soro fun Ọlọrun bi?”

Ọlọrun o! Jesu, Ọlọrun Ọrọ ti a fi han, O sọ wipe, “Bi o se ri ni ọjọ Sodomu,” aye yoo wà ni ipo yẹn, ni kete saaju iparun aye awọn Keferi, igba awọn Keferi. A ti wa nibẹ bayi, wọn ti di Sodomu patapata. Lẹyinnaa O sọ wipe Ọmọ eniyan, eyiti a maa n saaba tọka si gẹgẹbi “wolii,” ni a o fi han ni wakati yẹn. Mu ọrọ Rẹ sẹ, Ọlọrun. Awa, ọmọ Rẹ ti ó gbagbọ, a n duro pẹlu ọkàn tootọ, wipe ki O fun wa ni igbagbọ, Oluwa, ti o jẹ wipe, nigba ti a ba n gbadura, awọn eniyan yoo gbagbọ. Akoko asalẹ niyi, Baba. Jẹ ki imọlẹ asalẹ ti Ọmọ Ọlọrun (Ẹniti o ti wà, ti o si wà, ti o si n bọ̀ wá) fi ara Rẹ̀ han nipa asọtẹlẹ ti Ó ti sọ. Ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

73 Mo ti setan bayi lati gbadura fun awọn alaisan. Sugbọn ohun ajeji ni, nigbati a ba duro sibi, mo si duro sihin yi bayi, mo n pe awọn eniyan nija, ti wọn si n gbọ wa kaakiri orilẹ-ede yii, wipe Ọlọrun si jẹ Ọlọrun sibẹ. Ko lee kùnà, ati wipe ohun ti O ti seleri, ni yoo se. Ko lee kuna laelae lati se e, nitori O ti seleri lati se e. Nitorinaa, mo le fi gbogbo igbẹkẹle sinu ohun ti O sọ. Nitorinaa, mo n foju sọna si bibọ Rẹ, mo n foju sọna

wipe ki O farahan nigbakuugba, nitori O wipe, "Ni wakati ti ẹ kò rò, ti aye kò rò," nigbanaa ni Oun yoo farahan. Bayi, gẹgẹbi mo se mọ mọ….

Mo wà ninu Ile-ijọsin mi nihin, awọn eniyan diẹ ni o si joko sihin yii ti mo mọ. Arakunrin Wright, awọn diẹ ninu awọn ti o joko sihin, ati lẹgbẹ ibi yii, ni mo ṃo. Sugbọn ọpọlọpọ yin ni n kò mọ. Ko sì sí bi mo se lee sọ wipe Ọlọrun yoo se eyi ni asalẹ yii. A ti rii ti O n se e fun ọpọlọpọ ọdun sẹyin, sugbọn O le má se e ni asalẹ yii. N ko mọ. O kù sọwọ Rẹ̀; Aseyoowu ni. Ohun ti o ba fẹ ni O n se; ẹnikankan ko lee sọ ohun ti yoo se fun-Un. O dánìkan wà, ninu ifẹ Rẹ ati ni ọna Rẹ. Sugbọn nitori O ti se ileri rẹ, mo n beere wipe ki O se e. Kii se nitori tiwa, wipe a nilo rẹ, sugbọn boya nitori awọn alejo kan, ki Ẹmi Mimọ lee ta ami-ororo … bayi, ami-ororo le wa lori. Bayi, ko si bi O se ta ami-ororo le mi lori to, O nilati ta ami-ororo le iwọ naa lori pẹlu, dajudaju, lati gbagbọ.

74 Bayi, mo fẹ ni ila adura, mo si fẹ gbadura fun awọn alaisan bi mo ba se lee se to. Bayi, yala ki a ni ìlà kan, lati pe awọn eniyan ki a si mu wọn wa soke nihin, ila adura kan ki a si gbadura fun olukuluku ẹniti o n saisan nibi yii, mo lero bẹẹ, ki awọn oniwaasu ẹlẹgbẹ mi wa sibi pẹlu wa, ki wọn si gbe ọwọ le yin. Dajudaju, a lee se iyẹn. Tabi ki a beere lọwọ Baba wa, ti o jẹ wipe Oun nikan ni o lee se ohunkohun fun yin, nitori ọwọ temi dabi ọwọ ti ẹyin eniyan yii naa. Sugbọn ohun ti o wà nibẹ ni wipe, kii se ọwọ eniyan ni o n se e; Ọrọ Ọlọrun ni. Igbagbọ ninu Ọrọ yẹn ni o n se e. Ko si ohun imọ-ijinlẹ kankan nipa rẹ; gbogbo rẹ ko ba imọ-ijinlẹ rin.

Ko si ohun ija kankan ti Kristẹni ni, ti o ba imọ-ijinle mu. Njẹ ẹ mọ iyẹn? Ifẹ, ayọ, alaafia, ifarada, isoore, iwa tutu, iwa pẹlẹ, suuru, igbagbọ, Ẹmi Mimọ; gbogbo rẹ jẹ airi fun imọ-ijinlẹ. Iyẹn nikan si ni o jẹ otitọ ti o si pẹ kánrin-kése. Ohun gbogbo ti ẹ n ri wá lati inu ilẹ, yoo si pada sinu ilẹ. Sugbọn awọn ohun ti ẹ ko lee fi oju ri, sugbọn ti o n fi ara rẹ han, iyẹn ni aye ainipẹkun.

75 Se ẹ o gbagbọ, ti Ọlọrun ba fi ara Rẹ han, ki o si fihan wipe Oun wa laaye nihin, ti O si n se nkan kannaa ti o se ni atetekọse, lẹyin isẹ-ohun-Ọlọrun yii, se e o gba a gẹgẹbi iwosan yin? Ki Ọlọrun gba bẹẹ. Bayi mo fẹ ki gbogbo awọn ti o wà ninu ile, laibikita ẹni ti o jẹ tabi ibi ti o ti wa, mo n fẹ ki o gba isẹ-ohun-Ọlọrun yii gbọ wipe otitọ ni. Eleyi ni ohun-isẹ-Ọlọrun ti Ọlọrun ni ninu Bibeli Rẹ fun wakati yii, wipe Jesu Kristi wa nibi ni asalẹ yii, ati wipe O wa laaye. O fẹrẹ jẹ gbogbo….

Gbogbo ẹyin eniyan ni ẹ mọ̀ mí; ilu ti a ti tọ́ mi dagba ni mo wà yi. N ko tilẹ ni ẹko iwe girama. Otitọ gbaa niyẹn. Ẹ si ti mọ mi pẹ to, mo lero wipe mo ti gbe laarin yin lati fihan wipe mo je olootọ ati olododo. Emi kii se agabagebe. Awọn alatako mi paapaa kò sọ bẹẹ. Wọn kan n sọ wipe, "Iwọ kii se agabagebe, sugbọn o kan saa kuna ni. O kan saa kuna nitori aimọkan ni, kii se wipe o mọ̀." N kò rò wipe mo fi àìmọ̀kan kùnà, nitori Ọrọ Ọlọrun n jẹri si isẹ-iwaasu mi, o si yẹ ki o sọ fun yin, ẹni ti o jẹ. Ẹ si gbọ ti mo n sọ gbangba wipe kii se emi, nitorinaa, o nilati jẹ Oun. Se bẹẹ ni? Ẹ ni igbagbọ ninu Ọlọrun nigbanaa. Ẹ wo ibi yii, eyin ẹ gba Ọlọrun gbọ. Ti ẹ ba lee gba Ọlọrun gbọ, Ọlọrun yoo fi fun yin. Ti O ba lee se bi O se iyẹn se tẹlẹ, a jẹ wipe Ó jẹ Ọlọrun sibẹ. Se ẹ gba iyẹn gbọ?

76 Se ẹ gba a gbọ? Obinrin kan ti o joko siwaju mi, ti o n wo mi, pẹlu omije ni oju rẹ, tọkantọkan. N ko mọ ẹni ti ó jẹ, n ko ri i ri. Mo jẹ ajeji si ọ. Se o rò wipe Ọlọrun mọ asiiri ọkan rẹ, awọn ohun ti o fẹ, tabi ẹ̀sẹ̀ rẹ, tabi ohunkohun ti o jẹ? Se o rò wipe Ó mọ̀ ọ? Se o rò wipe Ó lee fi ohun ti ẹ̀sẹ̀ rẹ jẹ́ hàn mi, ohun ti o ti se, ati ohun ti kò yẹ ki o se, tabi ifẹ ọkan rẹ, ohunkohun ti ó jẹ? Ti O ba se e, se yoo jẹ ki o gba Á gbọ, ti o mọ wipe o nilati jẹ Oun? Se iwọ yoo gba wipe Oun ni? Kii se ẹ̀sẹ̀ rẹ lo n da ọ laamu; o ti jẹwọ iyẹn. Sugbọn o n fẹ baptisimu Ẹmi Mimọ Rẹ̀. Iwọ yoo rii gba. Mo rii ti ó sọkalẹ wá sori rẹ.

Ki ẹ lee mọ wipe mo n wo obinrin naa - oun n wo mi - mo fẹ fi Ẹmi Mimọ han yin. Ẹ wo ibi yii, taara ni ori obinrin kekere yii ti o joko si ibi ẹsẹ̀ mi nihin yii. Nigbati mo sọ iyẹn, ohun kannaa ti oun naa n fẹ niyẹn, ani baptisimu Ẹmi Mimọ. Se o gbagbọ wipe iwọ yoo rii gba, arabinrin? Na ọwọ rẹ soke, nigbanaa. N ko ri obinrin naa ri ni gbogbo ọjọ aye mi.

77 Njẹ ẹ ri ọkunrin yii ti o joko sibi yii, ti o dorikodo, ti o joko sibẹyẹn, pẹlu kọ́là asọ rẹ ti ko duro daradara lọrun rẹ, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Arun ile ìtọ̀ ni o n da ọ laamu. Se o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo mu ọ larada? Na ọwọ rẹ soke ti iwọ yoo ba gba a. O dara, ki Ọlọrun fun ọ ni ibeere rẹ.

Ọdọmọkunrin ti o joko sibi yii, ti o n fẹ baptisimu Ẹmi Mimọ. Se o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo fi fun ọ, pẹlu asọ tai funfun rẹ ti o rọ sẹyin? Ọlọrun yoo gba bẹẹ.

Ọkunrin ti o wa nibi yii n gbadura fun iyawo rẹ. O wà ni ile itọju awọn wèrè. Se o gbagbọ wipe Ọlọrun yoo wo o san, mu u lara da? Se o gba a gbọ? O lee rii gba.

Iwọ ti o fi ọwọ rẹ si ọfun rẹ, se o gbagbọ wipe Ọlọrun lee se iwosan ọkan rẹ ti o n da o laamu yẹn, ati inu rirun ti o ni yẹn? O joko sibẹ, o n kerora bayi. Se bẹẹ ni? Se o gbagbọ wipe O wò ọ san? Nigbanaa, o lee rii

gba. Amin.

78 Se ẹ rii, ọkannaa ni lana, loni, ati titi laelae. Ẹ beere lọwọ awọn eniyan wọnyẹn, ki ẹ wo o boya mo mọ wọn. N ko mọ wọn, sugbọn Oun mọ wọn. Amin. Njẹ ẹ ri imọlẹ yẹn ni ẹgbẹ ogiri nibẹyẹn, o duro lori ọkunrin kan ti o joko sibẹyẹn. Aisan eegun ẹyin ni o n baa ja. Kii se ilu yii ni ó ti wá; Georgia ni ó ti wá. Ọgbẹni Duncan, gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ, Ọlọrun yoo wo aisan ẹyin yẹn san. Se o gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan rẹ? Ki Ọlọrun bukun fun ọ.

Ọkunrin kan niyi ti o joko si ẹyin nibi yii, pẹlu aisan ẹyin didun, ti o n wo mi. Emi ko mọ ọ, sugbọn Ọgbẹni Thompson ni. Se o gbagbọ? Dide duro, lẹyin nibẹyẹn, ki ó lè jẹ wipe…. Ajeji ni mo jẹ si ọ. Bẹẹ ni. Sugbọn o joko sibẹyẹn, o n gbadura. A ti wo aisan ẹyin didun rẹ sàn bayi. Jesu Krsiti mu ọ larada.

79 “Imọlẹ yoo wà ni àkókò asalẹ.” Se ẹ kò rii ni, O wà nibi ni asalẹ yii. Oun ni EMI NI nla naa. Ọkanna ni lana, loni, ati titi laelae. Se ẹ gba a gbọ? Se o tẹ yin lọrun, o si da yin loju wipe eyi ni Jesu Kristi ti O n fi ara Rẹ han, ti O n fi ara Rẹ han ninu asọtẹlẹ?

Mase daamu nipa oju yẹn; Ọlọrun maa n wo awọn alaisan ati awọn ti a n daloro sàn.

Eniyan melo…. Ẹni melo lo wa nibi, ti o n saisan? Ẹ jẹ ki a ri ọwọ yin. O kan dabi ẹni wipe nse ni wọn n faa nihin ati lọhun. Njẹ ẹnikẹni ninu yin ni kaadi adura? N ko mọ bi mo se lee mu yin wa si ibi yii. Mo fẹ gbadura fun yin, n ko si mọ bi mo se lee se e. Se ẹ ri ohun ti…. Ẹ wo ara ogiri; bawo ni mo se fẹ mu wọn de inu ibẹyẹn? Njẹ ti a ba di alafo kan, ti a si tun di ekeji nibẹyẹn, ti olukuluku wa duro pa si oju kan.

80 Ẹ feti silẹ, ki ẹ gbọ mi. Njẹ mo sọ ohun kan fun yin ri ni orukọ Oluwa ti kò wá sí imusẹ ri? Se bẹẹ ni? Ohun gbogbo ni o ti ri bẹẹ. N ko fi igba kan beere owo lọwọ yin ri ni gbogbo ọjọ aye mi, tabi mo se bẹẹ bi? Ko si igba kankan. N ko fi igba kan gba ọrẹ ri ni gbogbo ọjọ aye mi. N ko wa si ibi nitori owo. N ko wa si ibi lati tan yin jẹ. Mo wa si ibi lati fi Ọrọ Ọlọrun ti akoko yii han ni. Mo ti sọ otitọ fun yin, Ọlọrun si ti jẹri wipe otitọ ni. Bayi mo sọ fun yin, “Bayi ni Iwe Mimọ wi,” wipe ti onigbagbọ ba gbe ọwọ rẹ le alaisan, Jesu wipe, “Ara wọn yoo dá.” Se ẹ gba iyẹn gbọ? Nitorinaa, niwaju Ọlọrun, se ẹ ko gbagbọ wipe yoo se e lọwọlọwọ bayi?

81 Bayi, ẹ gbe ọwọ le ara yin, ki ẹ si fi sibẹ fun isẹju kan. Bayi, ẹ mase gbadura; ẹ saa gbe ọwọ le ara yin. Ni ibi ti ẹ ti n gbọ wa … Emi funra mi pẹlu, mo gbe ara mi le awọn asọ ilewọ wọnyi. Bayi mo fẹ ki ẹ wo mi ni isẹju kan. Kini o kù ti Ọlọrun koi tii se? Ẹ wo bi O se … Ọrọ ti a ti ka, awọn asọtẹlẹ ti a ti sọ, wipe Jesu fi ara Rẹ han nipa awọn asọtẹlẹ. Bayi ẹ wo wakati yii, ati ọsẹ mẹta ti o kọja yii, ti a ti fi àkókò ti a n gbe inu rẹ han. Ẹ wo ohun ti a ti ka; nipa awọn wolii èké ati awọn isẹ-ami ti yoo fẹrẹ tan awọn ayanfẹ jẹ; bi a se fi Ọrọ naa han, bi ọlọrun iran yii se fọ ọkan awọn eniyan loju; ati bi Ọlọrun funra Rẹ se sọ nipa awọn asọtẹlẹ Rẹ wipe awọn nkan wọnyi yoo sẹlẹ ni iran Laodikea yii. Ko si ohun ti o kù ti a koi tii se. Ọlọrun wà nihin, Ọlọrun kannaa ti o ba awọn eniyan yẹn sọrọ ni ọna Emmausi, ti O fi ara Rẹ han nipa awọn asọtẹlẹ ti a ti sọ nipa Rẹ; O wà nihin ni asalẹ yii, O n fi iwalaaye Rẹ han nipa awọn asọtẹlẹ ti a ti sọ nipa iran yii. Ọkannaa ni lana, loni, ati titi laelae. Se ẹ lee gba a gbọ? Nitorinaa ẹ gbe ọwọ yin le ara yin. Mase gbadura fun ara rẹ, sugbọn bi o ba se fẹ, gbadura fun ẹni ti o gbe ọwọ le, nitori awọn naa n gbadura fun ọ. Ẹ wo ibi bayi, ẹ mase siyemeji.

82 Bayi, ka ni ẹ le e ri ohun ti mo n wo ni! Ẹ si mọ wipe n ko ni purọ fun yin, bi mo se duro sibi yii. Ti ẹ ba lee rii, ki igbagbọ yin si lee fa Ẹmi Mimọ nla yẹn, ti o duro si ofuurufu nibẹyẹn, ti imọ-ijinlẹ ti ya aworan Rẹ, ki ẹ si rii bi O se n lọ kaakiri inu ile yii, O n wa ibi ti yoo balẹ si, O n wa ibi idakọro kan. Ẹ saa gba a gbọ, arakunrin mi. O ti fihan nipa Iwe Mimọ ati bẹẹ bẹẹ lọ, wipe otitọ ni. Bayi, fi tọkantọkan gbadura fun ẹni ti o gbé ọwọ lé yẹn, awọn naa n gbadura fun ọ.

83 Jesu Nasarẹti ọwọn, gẹgẹbi a se mọ, Oluwa, nipa Ọrọ naa wipe O wa nibi, nipa ileri wipe O wa nihin: “Nibikibi ti ẹni meji tabi mẹta ba pejọ pọ si ni orukọ Mi, Emi wa laarin wọn nibẹ. Awọn ami wọnyi ni yoo si maa tẹle awọn ti o gbagbọ; ti wọn ba gbe ọwọ wọn le alaisan, ara wọn yoo da.” Nibiti afẹfẹ tẹlifoonu yi n fẹ de, jẹ ki Ẹmi Mimọ nla naa lọ si ipejọpọ kọọkan. Jẹ ki imọlẹ Mimọ kannaa ti a n wo ninu ijọ nihin, jẹ ki o ba lẹ̀ ẹnikọọkan, si jẹ ki wọn ri imularada ni asiko yii. A ba ọ̀tá wi, èsù, niwaju Kristi; a sọ fun ọ̀tá wipe a ti sẹgun rẹ̀ nipa ijiya ifirọpo, iku Jesu Oluwa ati ajinde isẹgun ni ọjọ kẹta. O si ti fihan, pẹlu idaniloju, wipe O wa laarin wa ni asalẹ yii, laaye, lẹyin bii ẹgbaa ọdun. Jẹ ki Ẹmi Ọlọrun alaaye kun gbogbo ọkan pẹlu igbagbọ ati agbara, ati agbara iwosan lati inu ajinde Jesu Kristi, ẹniti a fihan bayi nipa imọlẹ nla ti o n kaakiri inu ijọ bayi, ni iwaju Rẹ̀. Ni orukọ Jesu Kristi, gba bẹẹ fun ogo Ọlọrun.

Jẹ ki awọn asọ-ilewọ wọnyi ti a gbadura le lori, ki wọn lọ si ọdọ awọn alaisan ati awọn ti a n da loro, awọn ti o wà fún. Jẹ ki Ẹmi Mimọ kannaa ti o wa nihin, ti O n fi ara Rẹ han, ki O fi ara Rẹ han pẹlu lara gbogbo awọn alaisan ti a ba fi asọ-ilewọ yii lé. Je ki iwaalaye Ọlọrun kun ọkan wọn to bẹẹ gẹẹ pẹlu igbagbọ titi ti a o fi wo aisan àgọ́ ara wọn san. Eyi ni a beere fun ogo Ọlọrun, niwaju Jesu Kristi ati ni orukọ Jesu Kristi, bi awa iransẹ Jesu Kristi ti beere rẹ. Amin.

84 Bayi, lati inu ọkan yin wa emi kò bikita ohun ti o n se yin, lati inu ọkan yin wa, njẹ ẹ lee gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin wipe Ọrọ Ọlọrun ti fun yin ni ibeere yin? Mo gbagbọ wipe gbogbo ọwọ ni o lọ soke ti mo ri. Ti ẹ ba gba a gbo! Ẹ ranti bayi, o ti pari!

Ẹyin ti ẹ wa lori tẹlifoonu, ti ẹ ba ti gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin, gẹgẹbi awọn iransẹ Ọlọrun se n gbe ọwọ le yin, ti awọn olufe n gbe ọwọ le yin, ti ẹ ba gbagbọ pẹlu gbogbo ọkan yin wipe o ti pari, o ti pari naa niyẹn. Ẹmi Mimọ nla nni, O wa nihin ninu Ile-ijọsin ni asalẹ yii. Mo ri I ti o n rin lori awọn eniyan, O fi ara Rẹ han nibi yii lẹgbẹ ogiri, O si lọ sori okunrin kan, O tun sọkalẹ wa sihin, ati kaakiri gbogbo ile yii, O n fi awọn asiiri awọn ọkan han, ifihan iwalaaye Rẹ, lati fihan wipe ọkannaa ni lana, loni, ati titi laelae. O n bẹ laarin wa. Oun ni Ọlọrun, Ọlọrun ti kii kuna laelae.

85 Njẹ ọkan wa ko ha gbina ninu wa, njẹ ko ha gbina naa bayi, lati mọ wipe a wà niwaju Jesu Kristi ti o jinde, ẹniti ogo ati iyin wa fun titi laelae; ẹniti o jẹ aworan Jehofa Alagbara; ẹniti o sọkalẹ wa gẹgẹbi ọwọn ina ninu igbo ti o n jo, lati fa oju wolii kan mọra; ẹniti o sọkalẹ sori oke, ti ẹnikẹni ba si fọwọ kan-an yoo di pipa, yatọ si Mose ati Josua. Bi o se dari awọn ọmọ Israẹli la aginju ja, ninu irin-ajo wọn, gẹgẹbi apẹẹrẹ awọn eniyan ti a pe jade loni. Oun niyi nibi, nipa iwadi imọ-ijinlẹ, O tun fi ara Rẹ han niwaju imọ-ijinlẹ. Ati nipa awọn ise Rẹ ati asọtẹlẹ Rẹ̀, awọn ohun ti a sọtẹlẹ nipa Rẹ wipe yoo se lọjọ oni, lati mu ki o jẹ ọkanna lana, loni, ati titi laelae, ni a ti fi han ni pipe. Njẹ eyi ko ha to lati mu ki ọkan wa gbina jẹ ninu wa bi? Ki Ọlọrun bukun yin.

86 Bayi pẹlu ọkan kan, ẹ jẹ ki a dide duro ki a si sọ pe [Awọn ijọ n wi tẹle Arakunrin Branham.], Mo gba Jesu Kristi bayi gẹgẹbi Olugbala ati Oluwosan. Ati nipa oore-ọfẹ Rẹ, lati wakati yii lọ, Ọlọrun o, mase jẹ ki aigbagbọ kankan wọnu ọkan mi, nitori mo ti ri asọtẹlẹ ọjọ oni ti a mu sẹ. Mo gbagbọ wipe Jesu Kristi wa laye nihin bayi, O n fi idi Ọrọ Rẹ fun wakati yii mulẹ. Awọn asọtẹlẹ ti a ti kọ nipa Rẹ ni a ti mu sẹ bayi ni aarin wa. Oun ni Olugbala mi, Ọlọrun mi, Ọba mi, Ohun-gbogbo-ninu-ohun-gbogbo mi.

87 Ọlọrun ọwọn, gbọ ijẹri wa. Ki O si fi fun wa, lojoojumọ, ounjẹ ìyè. A si fi iyin fun Ọ, Ọlọrun, lati isalẹ ọkan wa wá. A yin Ọ, Alagbara nla, Ọlọrun awọn wolii. Ni orukọ Jesu Kristi. Amin.

Ah, iru akoko wo ni, igba wo ni!

…………. saa ti gbagbọ;

Saa ti gbagbọ, saa kan ti gbagbọ.

Ohun gbogbo ni sise, saa ti gbagbọ;

Ẹ jẹ́ ki a kọ ọ́ bayi:

Bayi mo gbagbọ, ah, bayi mo gbagbọ,

Ohun gbogbo ni sise, bayi mo gbagbọ;

Bayi mo gbagbọ, ah, bayi mo gbagbọ,

Ohun gbogbo ni sise, bayi mo gbagbọ;

Se ẹ̀rí rẹ niyẹn? Bayi bi a se tẹriba:

Titi ti a o fi pade! titi ti a o fi pade!

Titi ti a o fi pade lẹsẹ Jesu;

Titi ti a o fi pade! titi ti a o fi pade!

Ki Ọlọrun wa pẹlu yin titi ti a o tun fi pade!

[Arakunrin Branham n kun si orin “Titi A O Fi Pade!”]

………………lẹsẹ Jesu;

Titi ti a o fi pade! titi ti a o fi pade!

Ki Ọlọrun wa pẹlu yin titi ti a o tun fi pade!

88 Pẹlu ori wa ni titẹba, Arakunrin Vayle n duro sibi yii lati gba adura agbajade. Arakunrin Lee Vayle jẹ onkọwe fun Ile-ijọsin nibi, ti awọn iwe kika ati bẹẹ bẹẹ lọ. Arakunrin ọwọn ni, o ti wà pẹlu mi ninu awọn isọji ita gbangba. O wu mi ki n ni aaye lati jẹ ki gbogbo oniwaasu wá si òkè nihin ki wọn si bá a sọrọ. O da mi loju pe o ye yin. Gbogbo ẹyin oniwaasu, inu wa dun lati ri yin nibi. Gbogbo ẹyin ọmọ ijọ, awọn eniyan lati oniruuru ijọ,

ati awọn ti oku, inu wa dun lati ri yin nibi. O si jẹ adura wa fun gbogbo wa, wipe ki Ọlọrun wa pẹlu yin titi ti a o tun fi pade. Bi a se tẹriba ti a si gbe ọwọ wa soke, ẹ jẹ ki a tun kọ ọ́ lẹẹkan sii pẹlu ohun didun si Ọlọrun.

Titi ti a o fi pade! titi ti a o fi pade!

Titi ti a o fi pade lẹsẹ Jesu!

Titi ti a o fi pade! titi ti a o fi pade!

Ki Ọlọrun wà pẹlu yin titi a o tun fi pade.

MESSAGE hub online

www.messagehub.info

Ìwàásù lati ẹnu

William Marrion Branham

"... Ati ni ọjọ́ ohùn angẹli keje ..." Ifihan 10:7